Lakaye Ọrọ

OLUKULUKU ohun ni akoko wa fun, ati igba fun iṣẹ gbogbo labẹ ọrun. Igba bibini ati igba iku. Iran kan nlọ iran kan mbọ ṣugbọn aiye duro titi lai.

# Irohin Yoruba

No. 800 OCTOBER 5 — OCTOBER 11, 1960 Kobo Meji (2D.)



Dara fun Ejẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# NAIJIRIA DI OMINIRA


ZIK


SARDAUNA


AWOLỌWỌ


AKINTỌLA


BALEWA





*Aworan oke lọwọ osi yi ni ti igbati nwọn ta Asia Naijiria soke ni gbangba ọdan l'Eko Aworan ẹgbẹ ọtun l'oke yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Alexandra nfun Ọlọla Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria ni iwe ofin idominira Naijiria. Wo oju ewe keji ati ikejilelọgbọn fun awọn irohin ati aworan yoku.*

# Naijiria gba iwe ofin idiominira

OJO nla, ọjọ ayọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kini oṣu yi jẹ fun gbogbo awọn ọmọ Naijiria. Ọjọ ti a ko ni gbagbe ni ọjọ na — ọjọ ti ilu Naijiria gba ominira, ti o kuro loko ẹru, ti o si di ẹni ti yio ma sin ara rẹ. Ọjọ na ni Ọmọ-ọba Alexandra fun Naijiria ni iwe ofin idiominira ni gbangba ọdan.

Ipalẹmọ ominira na pọ pupọ, o si ti pẹ ti awọn ti nwọn wa nidi eto ajọyọ ominira na ti nfi ori k'ori lati le ri i pe ajọyọ na jẹ eyiti yio gbe orukọ ilu han.



Aworan oke iṣẹ oni ni ti ami ihamọra-ogun Apapọ Ijọba Naijiria. Aworan oke yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Alexandra nki Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba pinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ Eti ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi nibi ile eye ifihan Naijiria l'Eko. Wo oju ewe kejilelọgbọn fun awọn aworan yoku.




Lati ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹdindinlogun oṣu ti o kọja yi ni awọn alejo Apapọ Ijọba Naijiria ti bẹrẹ si wọ ilu Eko fun ajọyọ. Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrindinlogbọn si ni Ọmọ-ọba Gẹẹsi, Ọlọla julọ Alexandra de si ilu Eko gẹgẹbi aṣoju Ọba Gẹẹsi, Ọlọla-julọ Elizabeth Keji. Ni ọjọ ti Ọmọ-ọba yi ti de ni o ti nri ikẹ ati ayẹsi, lati ọdọ awọn ara ilu l'ọkunrin, l'obinrin, l'ọmọde ati l'agba.

Ẹnyin onkawe wa ti ka nipa ariya ti awọn ara ilu Eko ṣe fun Ọmọ-ọba yi ninu iwe Irohin Yoruba ti ọsẹ ti o kọja.

Iwe ti ọsẹ yi kun fun irohin ariya ti awọn ara ilu ti nṣe fun un lati igbati Ọmọ-ọba na ti de si ilu Eko.

Gẹgẹbi eto ti nwọn ti ṣe nipa bi yio ti ṣe gbadun ajọyọ ominira na si, Ọmọ-ọba yi ti pade awọn enia pataki pataki ni ilu, o si ti ri ohun nla ti nwọn ti pese silẹ fun un lati ri. O ti ri origirisi ere o ti wo origirisi iran. Gbogbo rẹ ni o si gbadun.

Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kọkandinlogbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn ọmọ ile-ẹkọ kekere ni ilu Eko ṣe ariya fun un ni gbangba ọdan. Ariya ọjọ na buaiya o le gongo, irohin ko to afojuba ni. Bakanna si ni ti ariya ọjọ keji ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja.

Ọjọ na ni Ọmọ-ọba Alexandra fi ipalẹ Ile Ominra tuntun (Independent Building) lelẹ ni opopo ọdan l'Eko ni agogo mẹsan owurọ. Ẹsẹ awọn Ọba, Ijoye ati awọn olori Ilọ ti Igbagbọ ati Imale ni Naijiria pe sibẹ. Ọmọ-ọba na sọrọ iwuri pupọ O ni inu on dun fun gbogbo ariya ti awọn ara ilu ti nṣe fun on, o ni on si

((Wo oju ewe ogbon)



Aworan yi ni awọn ero iworan ni gbangba ọdan ni ọjọ ikini oṣu yi, nigbati a ngba ominira ilẹ wa.



# Amẹrika ki Naijiria ku orire Ominira



Ọgbẹni Joseph Palmer



Ọlọla Nelson A. Rockefeller Gomina ilu New York, o jẹ asoju ti o wa fun ajọyọ ominira Naijiria

*Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"*





## Gbọn aisan awọ-ara rẹ nu loru ọjọ kan



Egbogi titun ti nwọn sẹṣẹ fi ọgbọn ijinlẹ wari bẹrẹ si fi opin si awọn aisan ekuru, rorẹ, lapalapa, ogodo, ekusa ati isaka-ẹsẹ loojọ—Onsiṣẹ lẹ nigbati o ba sun.

NIXODERM jẹ egbogi [illegible] ... Ekuru, Rorẹ, Afasiru, Lapalapa, Ogodo, [illegible] ... NIXODERM [illegible]

[illegible] ... NIXODERM [illegible] ... NIXODERM [illegible]

**NIXODERM**

# ỌRỌ-OLOTU

## IBUKUN NI FUN OJU TI O RI EYI

IBUKUN nlanla ni fun ẹniti gbigba Ominira Ijọba Apapo Naijiria yi ṣ'oju emi re. Ọpọlọpọ ni awọn enia ti nwọn nreti ọjọ na sugbọn ti aseko na ko ṣe oju won. Awa ti a wa ni aiye ti asiko na si soju wa ti a si tun je alabapin ninu ayọ Ominira o ye ki a fi ọpẹ fun Olorun. Ki a si gbadura si Olorun ki o tunbo fun wa ni emi-gigun ati alafia ara lati fi gbadura idera Ominira na.

Tani o mo iyi Ominira? Bi a ba ti fi adie si inu aro fun ojo pipe, ti a ba si i sile, a fo jade peerepe, pe on nri ominira, bi obirin ba wa ninu oyun, ojo ti o ba bi ọmọ a yọ yọ pe on ri Ominira, eniti ijoba ba mu pelu awon arufin, ti nwon ba ye oran ejo tire wo, ti adajo ba si da a sile kuro larin awon arufin, a jade ninu kotu pelu ope pe "mo dupẹ! mo dupe!! mo dupe lowọ Olorun!!! Bẹni eniti o ti wa ninu aisan fun ojo pipe, ojo ti o ba san, a mo iyi Ominira, beni eru ti o ba ra ara tabi iwofa ti o bọ okun gbese kuro lorun ati be ẹ be e lo titi.

Ọpọlọpọ awon ti oye ku die fun, ti nwọn ko si ri iru adanwo ti a so si oke yi ri ko mo iyi Ominira ti a gba, nitori ti Ominira na je ti gbogbo wa ni Naijiria ti ki i se fun ẹnikan soso ti a da sile kuro ninu ipọnju, awon miran tile nso pe kini anfani ti a le ri ninu Ominira yi ti a ko kuku jeki awon oyinbo ma a jọba le wa lori nitori Enia-dudu ni ika ninu ju obo lọ. Nitootọ Enia-dudu ti o ni ika ju obo lo wa, sugbon ki iwa ika won le de opin ni a se gba Ominira yi.

Bi iwa ika, awon osika yio se de opin ati bi Ominira yio ti se fa ire wọle fun gbogbo wa ti a o fi ni idera, owo ara wa ni a o fi fa a. Ohun ti a ni lati bere si se ni ki a mo iṣe wa ni iṣe, ki a maṣe ṣe ole. Ki a maṣe fi okan si a ti ri owo ifa, a ti fi okan si owo ifa ni nemu elomiran di ole nibi ki o rira a kiri ile ibiti nwon nta-tete kiri, bi o ba ta bi ko ba jẹ, a bere si i ma a jale, a di ogboju ọlọsa, danadana, gunbe-gunbe, agba dulumo, ajomọgbe ati be e be e lo.

Bi a ba tele inase bi awọn oyinbo ti o ko wa de aye Ominira ti nse nlo pelu ara wọn, a o gbadun Ominira ki a feran gbogbo ara wa bi omo iya kanna, ki a maṣe dale ara wa ki a maṣe seru pelu ara wa, ki o si gbekele ara wa, nitori aisootọ ati aini-igbekele si ara eni je nataki arun buruku ti ko ti jeki Naijiria wa ni Ominira. "Adie da ni ni ogun nu a fo o levin" ati ife-ti-ara eni nikan, laika ife ilu eni si, gbogbo iwa aleebu wonyi ni lati parun, okunkun Ijoba Naijiria atijo ti o ti koja lo, ki a si gbe aso imole Ominira titun yi wo.

Ki a ni ife ara wa laiya ẹya ilu kan sọlọ pe Hausa ni eyi, Ibo ni eyi, ki ise ara wa, iyen ko ṣiṣẹ ni inu Ominira ti a wa yi. Bi a ba ti so Apapọ Naijiria di okan ki gbogbo iṣesi wa si je okan, ki ero wa si sokan lati ma a lepa ilosiwaju orile-ede. Ki o maṣe je kiki ngo sise de awọn omo ki iya ma ba a je won lehin ola nikan ni a o ma lepa nitori eyi ni o poju ninu iwa Enia-dudu.

Yoruba ni "arise ni arika, arika ni baba iregun." Owo ifẹ ati irẹpọ ti a ba fi lelẹ ninu Ominira yi ni awọn iran ti mbo yio tele ti nwon yio si fi ma a gbe orile-ede wa ga. Ki onikaluku ki o sa agbara re, ki a ma ka ara wa kun nko koku nṣe oṣelu, nko si nibẹ bi nwon ba ti le se ki nwon ki o ma a se nso." Bi o ko si ninu asoju Igbimọ ilu, ti o ko nṣe kansilọ, mu imoran ti o ba ri pe o to fun idagbasoke ilu wa ki a ba e fi sinu Iwe IROHIN YORUBA ki gbogbo araiye gbọ ohun rẹ.

Ibukun ni fun oju ti o ri eyi.

# Mo kan saara si Oloye Awolọwọ

INU mi yio dun bi Olotu Iwe IROHIN YORUBA ba le gba mi laye lati kan saara si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria fun ọrọ iṣipade ti o fi ṣi ipade Ajọdun keje ti a ṣe l'Ẹko ni aipẹ yi.

Gẹgẹbi mo ti jẹ ọkan ninu awọn Ikọ ti o wa si ipade na, ẹtọ mi ni pe ki nfi ye gbogbo awọn enia pe laakaye ati imọ iṣelu Oloye Awolọwọ tubọ nga lọ siwaju si i ni. Eyi fihan daju gbangba pe Oloye Awolọwọ ni o le ṣe aṣiwaju oṣelu Apapọ Ijọba Naijiria fun idagbasoke ilu ju ti awọn aṣiwaju Ẹgbẹ oṣelu miran lọ, ti a ba nfẹ ẹkun-rẹrẹ alafia ati idẹra Ominira Ijọba ti a gba yi.

Mo si tun kan saara si Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati 'Gbakeji Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre fun ọgbọn ati oye ti o fi nṣe eto iṣelu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, omi ko yatọ si ọti ni iṣẹ iṣelu on pẹlu Alakoso Ijọba Iwọ-Orun takọkọ.

Emi ni,

**Prince Y. Ade Atiba,**
Ibadan.



Aworan yi ni igba ti Ọmọ-ọba Alexandra ngbọwọ lọwọ Ẹni-ọwọ-julọ A. W. Howells, Bişọbu Anglican l'Ẹko, lẹhinti nwọn ti ṣe isin tan ni Cathederal Church l'Ẹko ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi



# Ọwa Ilesha di alakoso Igbimọ awọn Ijoye Ipinlẹ Iwọ-Orun

NINU ipade Igbimọ awọn Ijoye Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn ṣe ni Ibadan ni ọjọ 'Rū ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja yi Ọba Alaiyeluwa Biladu Keji Ọwa Ilesha ni nwọn mu ni alakoso Igbimọ na, nwọn si fi Ọba Alaiyeluwa Ẹwi Ado Aladesanmi Keji ṣe Igbakeji Alaga.

Ni ọjọ ipade na ku ọla ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti ṣe ikede pe awọn Ijoye mẹrin tuntun ti di mẹmba Igbimọ awọn Ijoye Ipinlẹ Iwọ-Orun. Awọn na ni: Oloye Dọkita Akinọla Maja, Jagunmolu Ijaiye, Oloye Rotimi Williams, Apesin Itoko, Abẹokuta, Alhaji S. O. Gbadamosi, Ọtun Ikorodu ati Ọba Alaiyeluwa Samuel Akinsanya, Ọdẹmọ Iṣara.


Ọlọla Adesoji Aderẹmi, Ọni Ifẹ, Gomina, Ipinlẹ Iwọ Orun

Ninu ipade Ile Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ kanna ti Igbimọ awọn Ijoye pade, Ọmọ-ọba Adeleke Adedoyin ni nwọn tun yan ni Alaga Igbimọ na. Ọgbẹni T. L. Adelẹgan aṣoju iha ariwa Ilesha ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni nwọn yan ni Igbakeji Alaga.

Aworan oju ewe yi ni ti awọn Ọba ti nwọn jẹ mẹmba Igbimọ awọn Ijoye na gẹgẹbi ẹtọ wọn. Alaiyeluwa Ọni Ifẹ ni Alakoso Igbimọ na ki o to di Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun.


ALAFIN


ỌWA BABA EGBE


ALAKE


AWUJALE


AKENZUA


OLU WARRI


OLOWO


OLUBADAN


AKARIGBO


KO SI ẸNITI O BỌ LỌWỌ

OTUTU IBA












DỌKITA SỌ WIPE






Da OTUTU IBA rẹ duro

Jẹ ki o gbe koro

"ASPRO" mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# Ọmọ-Ọba Alexandra ba Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun sọrọ lori ẹrọ isọrọ sokere



OLỌLAJULA Ọmọ-ọba Alexandra si Ile-ẹrọ Isọrọ-sokere Posu ofisi Nla ni Opopo Ehingbẹti ni agogo mẹsan koja iṣẹju mẹdogun ni arọ ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kejidilọgbọn osu ti go mẹsan koja iṣẹju mẹdo-titun na sọrọ si Ọlọla Oba Adesoji Aderẹmi, Ọni Ifẹ, Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni Ibadan.

Wọnyi ni ọrọ ti Ọlọlajulọ Ọmọ-ọba Alexandra ati Gomina na fi ẹrọ titun na ba ara wọn sọ larin Eko ati Ibadan.

GOMINA—Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ni o wa nihin.
ỌMỌ-ỌBA—E ku owurọ o
GOMINA—Ku-owurọ o, Iyaafin Ọlọla Ọmọ-ọba, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi lati ba nyin sọrọ.
ỌMỌ-ỌBA—O dun mọ mi pupọ lati ṣe bẹ ẹ

Aworan yi ti igbati Ọmọ-Ọba na mba Gomina sọrọ.






Aworan oke yi ni ti awọn Ọlọkọ Ajẹ ti nwọn ṣere ni Ebute Ehingbẹti ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi fun ti ajọyọ Ominira.

* * *



Aworan oke yi ni igbati Ọmọ-ọba Alexandra de si Eko ti Ọgbẹni Bovell nki Ọmọ-ọmọ na ku-abọ.

## Ọkunrin kan ṣubu lulẹ, o si ku si ita gbangba

OSHODI.

Bi giripa ọkunrin kan ti nrin rekọja lọ ni opopo ode Brown, (Brown Street) t'o si rin de iwaju ojude ile Ọgbẹni Brown na ni Teṣan Oshodi ni deede agogo marun owurọ ọjọ Eti ti ṣe ọjọ kẹrindilogun oṣu yi ni o ba digbolulẹ lojuji ti ko si le da dide mọ.

Lẹsẹkẹsẹ na ni gbogbo awọn ero ona ati aladugbo ba figbeta, okiki si kan yi ka gbogbo adugbo ti gbogbo enia pe le e lori.

Bi awọn Olopa ti gbọ irohin na ni nwọn ba sare wa sibẹ, nwọn yiri rẹ wo, nwọn si ri i pe o ti ku, nwọn tu ara rẹ wo, nwọn ba owo ponun meta ati nain (£3. 0. 9d) pelu kọkọrọ ile rẹ n'apo rẹ ti nwọn wadi orukọ rẹ lọwọ awọn ti o duro nibẹ ṣugbọn ko si ẹniti o mọ ọ rara, ni awọn Ọlọpa ba gbe oku rẹ lọ si Teṣan Olọpa ki nwọn to tibẹ gbe e lọ si Lakulaku Ile-iwosan fun ayẹwo iwadi iku rẹ.

Awọn Ọlọpa si wa lẹnu ofintoto iwadi ohun ti o ṣekupa ọkunrin na.

Oluwa ṣere gba wa lọwọ iku akọṣẹku o.

Jan

LAKUREGBE!

ni kumọ nla kan



Masẹ jẹ irora lakuregbe lọ [illegible] mọ. Lo ALGESAL ki o si gbon irora na danu. ALGESAL [illegible] ni o ni Dimitat-[illegible] iyanu aporo idi [illegible] fun iwosan atorunwa ti yio wo inu ara de isale dada. O si ohun ti o le di ALGESAL lọwọ. Ara [illegible] ati ara gigan yio lọ. O bọ lọwọ irora ayanilara [illegible] rẹ yio [illegible] pe o ti lo egbogi ipara ALGESAL BALM.

Ra apo rẹ [illegible] loni.
Ogbọn [illegible] ti nwọn fi dan ALGESAL wo ti fihan pe o nwọ ara [illegible] ni igba meta o nyara [illegible] ni igba meta ju awọn egbogi ipara miran lọ.

ALGESAL

ipara pe iwosan ni igba meta

NIGERIAN EXHIBITION
October 1st-22nd
STAND 168

Gbogbo awọn [illegible] ni ALGESAL.

O [illegible] fun iwosan Lakuregbe, Arinka, Pulapala, Aisan-Wodi-Wodi, Lakuregbe-Ibadi, Lakuregbe Wosewose, Arogun, Lakuregbe-Arungun, Oluto agbari.




B.P.I. Ltd., [illegible]

# ITAN EKO (2)

## (Lati ọwọ Alhadji Y. A. Disu)

OBINRIN kan mbẹ ni Iddo laseko itan yi, oruko rẹ a ma a jẹ Aina. O ni owo pupọ, ola rẹ poju ti gbogbo obirin ẹlẹgbẹ rẹ lọ.

Awọn ara igbaani mba a jẹ, nwọn ni o ni ẹiyẹ aje, nwọn si taku pe ki o ga fi ilu silẹ fun wọn. Nigbati nwọn si wa lẹnu ọran yi ni awọn enia Ọlọfin pa ewurẹ kan ninu awọn ẹran ọsin obinrin na.

Obirin yi dide lọ sọ fun Ọlọfin ohun ti awọn enia rẹ ṣe si i. Ọlọfin si fi esi pe, "bi awọn enia mi ba pa ẹran rẹ nkọ, kini o le ṣe?" Obirin na si fi ibinu fi Iddo silẹ lọ ilu Ọba Ibini. O sọ irohin gbogbo ohun ti o ṣẹlẹ yi fun Onibini, nigbati o de ọdọ rẹ.

**ONIBINI BẸRẸ OGUN**

Ọpọlọpọ igba ni Onibini nran awọn ọmọ ogun rẹ lọ si Iddo pẹlu awọn Balogun rẹ mẹtẹta, Aṣeru, Akigbida ati Ọlọrungbiwa lati koya fun Aina. Ọlọfin ati enia rẹ si ni o nṣẹgun.

Nikẹhin ni "Ayaba" Ọlọfin ti a npe ni Ajaye da Ọlọfin ati Iddo. O gbe ibọdi awọn ara Ibini nipa fifi idi agbara ọkọ rẹ han awọn ọmọ-ogun Onibini. O gba oogun'bajẹ lọwọ awọn ọta ilu rẹ, o si da a sinu gbogbo oogun ti ọkọ rẹ fi npe agbara jagun.

Idi ti obirin na fi dalẹ ni pe, awọn ọmọ-ogun Ibini tan a njẹ pe, ti o ba ran awọn lọwọ ṣegun, awọn yio fun un ni ọpọlọpọ ilẹkẹ iyun.

**OGUN MU ỌLỌFIN**

Nigbati nwọn si ṣegun ara Iddo tan, awọn ọmọ-ogun Onibini mu Ọlọfin lọ si ọdọ Ọba wọn, ṣugbọn Onibini ko pa Ọlọfin. O paṣẹ pe ki nwọn fi i sinu ile kan ti ko ni oju ti ogiri rẹ si ga pupọ, ki ebi le le p a a ku si ile na.

Lẹsẹkẹsẹ, nwọn mu aṣẹ Ọba na ṣẹ. Ṣugbọn nkan-kan ko ṣe Ọlọfin f'ọpọlọpọ ọjọ ti o wa ninu ile yi. Kanran ki Ọlọfin ku, okiki ariwo ọja ni awọn ara ilu ngbọ lati inu ile na wa. Nwọn si lọ sọ ohun iyanu yi fun Ọba, on na wa si itosi ile na, o fi eti ara rẹ gbọ okiki ati ariwo na.

Nigbati Ọba Ibini wọ ile na ti o si fi oju ara rẹ paapa ri i pe Ọlọfin ko ku, o pe e ni engmọ, o si da a silẹ. Ki Ọlọfin to pada wa si Iddo ni olobo ti ta a pe Ajaye obinrin rẹ ni o ṣe iṣẹ ibi na ti ọwọ ọmọ-ogun Ibini fi le tẹ on, o si bẹ Ajaye lori nigbati o pada de Iddo.



ALHADJI Y. A. DISU

* * *

Ajaye ko ku, akeku rẹ si nrin kakiri gẹgẹ bi ẹnipe ori rẹ mbẹ l'orun rẹ, gbogbo enia si fẹran lati ma a lọ wo o pẹlu iyanu. Ọkan ninu awọn ọrẹ Ọlọfin ti a npe ni Aluworo tabi Olawọn wa ki Ọlọfin ku abọ ọjọ, ni ọjọ kan o si ri akekubọ Ajaye ti o nrin kiri leti ebute.

O ṣe abere nipa rẹ, nwọn si sọ fun un bi o ti ṣe ri bẹ ẹ. Oluwẹn fi agbara oogun rẹ paṣẹ fun akekubọ Ajaye pe, ki o wọ omi lọ; lẹsẹkẹsẹ o si wọ omi lọ.

Lati ọjọ na lọ ni a ti npe ibu omi jinjin ti Ajaye wọ lọ ni "Ibu-omi Ajaye". Bi ẹnikẹni yio ba si bura ni Iddo, a ma a wipe, "bi mo ba ṣe nkan na, ninu Ibu omi Ajaye ni ki nku si". O ti di ohun ibura.

Ọkunrin alagbẹdẹ kan ti a npe ni Ogunjasa mbẹ ni Iddo lakoko na. Nigbati awọn Ibini mu Ọlọfin ni igbekun lọ si Ibini, inu rẹ bajẹ pupọ ju, o bajẹ gidigidi tobẹ ẹ gẹẹ ti o fi wọ omi lọ. Nitorina ni nwọn ti fi ṣegun ni Iddo pe, ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe agbẹdẹ nibẹ mọ. Agbami ti o binu wọ lọ ni a npe ni "Agbami-Ogunjasa" Nigbati aiye di aiye Gẹẹsi ni nwọn bẹrẹ si kọle arọ si Iddo.

Ọlọfin gbe Iddo fun ọpọlọpọ ọdun titi ọjọ ti o wọ inu ibu-omi aya rẹ, Ajaye lọ. Awọn ẹni mẹtẹta ti a daruko ti a si sọ itan wọn yi jẹ awọn enia nla laseko tiwọn ni Iddo, tobẹẹ gẹẹ lẹhin iku wọn, bibọ ni ọpọlọpọ awọn enia mbọ wọn bi oriṣa, awọn si ti di irunmalẹ si Iddo.

**ỌBA IBINI DA AṢẸRU LỌLA**

Lẹhin iṣẹgun awọn ara Ibini lori awọn ara Iddo, akọni Balogun ti a npe ni Aṣẹru, ọkan ninu awọn ara Ibini a ma a gbogun lọ si ilu Awori, a si ma a ṣegun wọn. O ni igboiya o si ni ọmọ-ogun pupọ. O jagun molu titi de ilu Isẹri, nibẹ ni o ku si.

Awọn ara Isẹri ko jẹ sin oku rẹ si ilu wọn; nitoripe iranṣẹ nla ti Ọba Ibini ni iṣe. Aṣipa si gb'oku Aṣẹru lọ si Ibini. Inu Onibini dun si Aṣipa pupọ fun ohun ti

(Wo oju ewe kẹdọgbọn)


## Itan Ti Julius Sọ Lori Oti Waini Ti O Nfunni Ni Ilera

*Ẹ Ka nkan ti oti Atẹjẹsẹ* PHOSFERINE TONIC WINE *ṣe fun Julius Ajayi ti ongbe, 3, Akintoye Street, Yaba, Lagos.*



**Lọ Si Sọbu Ibiti O Ti Nra Ọja Kiakia ki O Si Ra Ọti Waini Atẹjẹsẹ, PHOSFERINE TONIC WINE Fun Ara Rẹ**

*Maṣe gbagbe lati yi ero bọọro magbesi rẹ (Radio) si si ibiti O ti le gbọ "Famous Fortunes", awọn itan ti wọn sọ bi a ti le si iyege ninu gbogbo akan ti ọka mọ.*

# "Iwa biti-biti ko jẹ ki Ẹgbẹ onișowo Ipinlẹ Ila Orun ni ilọsiwaju"

ENUGU.

NINU ipade ajọdun karun ti Apapọ Ẹgbẹ Ajumọșepọ Onișowo Ipinlẹ Ila-Orun (Eastern Nigeria Cooperative Congress) șe ni ilu Enugu laipẹ yi, Oloye J. U. Nwodo, Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Aje Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun so fun ipade na pe, aimeto iṣẹ aje, iwa bitibiti ati aisotitọ nipa ọran owo ni o mu ifasẹhin ati ainilọsiwaju ba ẹgbẹ na, o sọ rọ gbogbo ẹgbẹ na pe ki nwọn parapọ fi ọwọ-sowo wo arun aisotitọ na san.

Minista na si șe alaye pe, lotitọ, Ijọba ka Ẹgbẹ Onișowo na si pataki, o si fẹ șe iranlọwọ diẹ fun un, șugbọn idagbasoke ati ilọsiwaju ẹgbẹ na ku si ọwọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na.

Ọgbẹni D. E. Ebe, Olori ẹgbẹ na sọ ninu ọrọ rẹ pe, ẹgbẹ na ti nșe eto ilọsiwaju pataki fun ẹkọ ati Eto Ikede Irohin ẹgbẹ na pẹlu. O tun sọ fun awọn Ikọ ti o wa si ipade na pẹlu pe awọn ẹgbẹ t'on ti fi ọgọrun pọnun (£100) ranșẹ s'awọn ẹlẹgbẹ wọn ti o wa ni ilu "Chile" nibiti iṣẹlẹ nla kan gbe ṣẹlẹ laipẹ yi, o si tun sọ fun wọn pe, Adapọ Ajumọșepọ Ẹgbẹ Onișowo awọn orilẹ-ede (International Co-operative Alliance) ti fi Ẹrọ-itẹwe kan ta ẹgbẹ awọn lọrẹ.

## Aṣoju Ijọba Amẹrika ki Naijiria ku orire

OGBẸNI John K. Emmerson, Aṣoju Ijọba Amẹrika ni Naijiria ba awọn ọmọ Ẹgbẹ Akẹkọ ilu Amẹrika sọ ọrọ iwuri ni Ẹnugu ni ọjọ Abamẹta ti ișe ọjọ kẹwa oșu ti o kọja yi nipa eto iranlọwọ ti Amẹrika nșe fun ilọsiwaju ilu Naijiria.

Ninu akọsọ ọrọ rẹ Ọgbẹni Emmerson ki Naijiria ku orire ti Ominira ilu na, o ni on fi t'ọkan t'ọkan ba gbogbo awọn ara ilu na yọ.



JOHN K. EMMERSON

* * *

Ọgbẹni Emmerson si șe alaye nipa itan ati igbesiaiye ọmọ enia ati bi ẹkọ ti jẹ pataki fun ọmọ enia. O ni aini ẹkọ i ma a mu enia șișe ni. O ni on ni ero pe, awọn ọmọ Naijiria ti o lọ kọ ẹkọ ni Amẹrika ni ẹtọ lati șe igberaga nipa ẹkọ ti nwọn ni nibẹ.

Ọgbẹni Emmerson sọ pe ninu ọdun 1636 ni nwọn da "Harvard College" ti orukọ rẹ kakiri aiye, silẹ ni ilu Amẹrika ati pe ninu ọdun 1647 ni ilu Massachusetts ni nwọn kọkọ șe eto ọna bi nwọn yio ti șe ma a kọ awọn enia ni iwe dada. O si ni inu on dun lati ri i pe Amẹrika șe iranlọwọ pupọ an nipa ile iwe giga-julọ ti nwọn kọ si Nsukka ni Naijiria.

Ọgbẹni Emmerson na tun fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ yi pe awọn ara Amẹrika ti șe tan lati ran Naijiria lọwọ dada ninu ohun ọgbin, bi nwọn ti șe sișẹ ọgbin dada de aye ti nwọn yio ma a fi hu pupọ.

O ni awọn ara Amẹrika mẹtala ti nwọn ni imọ ijinlẹ nipa iṣẹ ọgbin ni nwọn ti de si Naijiria ati pe awọn mẹwa miran si tun mbọ wa si Naijiria fun iranlọwọ nipa iṣẹ na. O ni awọn ti nwọn ti de ti bẹrẹsi șișẹ ọgbin na nwọn si ti nfi ọna ti nwọn fi șe e han awọn ara Naijiria ti nwọn wa lẹnu iṣẹ na ati awọn ti nwọn nkọ ọ lọwọlọwọyi.

Ọgbẹni Emmerson șe alaye ninu ọrọ rẹ pe o ti to ọgọrun awọn ara Naijiria ti awọn ara Amẹrika ti kọ ni iṣẹ ọgbin ni akọyọri. Ni ipari ọrọ rẹ, o ni inu awọn ara Amẹrika ati Ijọba Amẹrika dun si Ominira Ijọba Naijiria gidigidi nitoripe ẹtọ wọn ni irufẹ Ijọba na. O si sọ pe yio dunmọ Amẹrika lati șe iranlọwọ ti o ba tọ si Naijiria ti o ba bere fun un ku orire.

## Adeșọkan jẹ oye Balẹ Ilobi

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti ișe ọjọ kejila oșu ti o kọja yi ni Ọba Alaiyeluwa I. B. Akinyẹle, Olubadan Ibadan fi Ọmọ-ọba Yesufu Ayilara Adeșọkan, ẹni ọgọta ọdun ọmọ Iba Oluyọle Ibadan jẹ oye Balẹ Olobi Ọja'ba Ibadan rọpo Ologbe Oloye Raji Maganna ti o ku ni nkan oșu kẹfa sẹhin.

Oloye titun yi ni baba Ọgbẹni A. O. Adeșọkan ti o ti wa ninu awọn Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti ana ri. Ẹsẹ awọn Oloye ati gbajumọ ni o si pe ṣọṣọ si ibi aṣẹyẹ na, Oloye titun na ati awọn ọmọ rẹ si fi ijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Oye a mọri o.




IWOSAN RỌRUN TO BẸẸ GẸẸ
PẸLU SANATOGEN

Agbara ati okun-inu nwa lati inu eelo-egbogi afunnilora ati afunnilokun—Sanatogen ni mejeji papọ—o jẹki enia taagun ki o si ni ẹran lara. Sanatogen yio fun ọ ni ẹkun agbara—ti o jẹ oranyan fun ogo.

Gbogbo awọn dọkita agbaiye ti sọ pe o dara
**BERE TIRẸ LONI**
O wa ni arowọlo ni awọn Ile-egbogi ati Ile-itaja yika gbogbo Naijiria.
Awọn Ẹgbẹ Onișowo ti o npin in kakiri ni MAJOR & CO. (NIGERIA) LTD.

**Lakaye Ọrọ**

OLUKULUKU ohun ni akoko wa fun, ati igba fun iṣẹ gbogbo labẹ ọrun. Igba bibini ati igba iku. Iran kan nlo iran kan mbọ ṣugbọn aiye duro titi lai.

# Irohin Yoruba

No. 800 OCTOBER 5 — OCTOBER 11, 1960 Kobo Meji (2D.)




**Dara fun Ẹjẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun**

O wa fun tita kakiri Ile-ẹgbogi

# NAIJIRIA DI OMINIRA



ZIK



SARDAUNA



AWOLỌWỌ



AKINTỌLA



BALEWA





*Aworan oke lọwọ osi yi ni ti igbati nwọn ta Asia Naijiria soke ni gbangba ọdan l'Eko Aworan ẹgbẹ ọtun l'oke yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Alexandra nfun Ọlọla Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria ni iwe ofin idominira Naijiria. Wo oju ewe keji ati ikejilelọgbọn fun awọn irohin ati aworan yoku.*

# Naijiria gba iwe ofin idiominira

OJỌ nla, ọjọ ayọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kini oṣu yi jẹ fun gbogbo awọn ọmọ Naijiria. Ọjọ ti a ko ni gbagbe ni ojo na — ọjọ ti ilu Naijiria gba ominira, ti o kuro loko ẹru, ti o si di ẹni ti yio ma sin ara rẹ. Ọjọ na ni Ọmọ-ọba Alexandra fun Naijiria ni iwe ofin idominira ni gbangba ọdan.

Ipalẹmọ ominira na pọ pupọ, o si ti pẹ ti awọn ti nwọn wa nidi eto ajọyọ ominira na ti nfi ori k'ori lati le ri i pe ajọyọ na jẹ eyiti yio gbe orukọ ilu han.



Aworan oke lọwọ osi ni ti ami ihamọra-ogun Apapọ Ijọba Naijiria. Aworan oke yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Alexandra nki Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba pinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ Eti ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi nibi ile ẹyẹ ifihan Naijiria l'Eko. Wo oju ewe kejilelọgbọn fun awọn aworan yoku.

Lati ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹdindinlogun oṣu ti o kọja yi ni awọn alejo Apapọ Ijọba Naijiria ti berẹ si wọ ilu Eko fun ajọyọ. Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn si ni Ọmọ-ọba Gẹẹsi, Ọlọla julọ Alexandra de si ilu Eko gẹgẹbi aṣoju Ọba Gẹẹsi, Ọlọla-julọ Elizabeth Keji. Ni ọjọ ti Ọmọ-ọba yi ti de ni o ti nri ikẹ ati ayẹsi, lati ọdọ awọn ara ilu l'ọkunrin, l'obinrin, l'ọmọde ati l'agba.



Ẹnyin onkawe wa ti ka nipa ariya ti awọn ara ilu Eko ṣe fun Ọmọ-ọba yi ninu iwe Irohin Yoruba ti ọsẹ ti o kọja.

Iwe ti ọsẹ yi kun fun irohin ariya ti awọn ara ilu ti nṣe fun un lati igbati Ọmọ-ọba na ti de si ilu Eko.

Gẹgẹbi eto ti nwọn ti ṣe nipa bi yio ti ṣe gbadun ajọyọ ominira na si, Ọmọ-ọba yi ti pade awọn enia pataki pataki ni ilu, o si ti ri ohun nla ti nwọn ti pese silẹ fun un lati ri. O ti ri origiriṣi ere o ti wo origiriṣi iran. Gbogbo rẹ ni o si gbadun.

Ni ọjọ Ojọbọ ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn ọmọ ile-ẹkọ kekere ni ilu Eko ṣe ariya fun un ni gbangba ọdan. Ariya ọjọ na buaiya o le gongo, irohin ko to afojuba ni. Bakanna si ni ti ariya ọjọ keji ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja.

Ọjọ na ni Ọmọ-ọba Alexandra fi ipalẹ Ile Omiinra tuntun (Independent Building) lelẹ ni opopo ọdan l'Eko ni agogo mẹsan owurọ. Ẹsẹ awọn Ọba, Ijoye ati awọn olori Ilọ ti Igbagbọ ati Imale ni Naijiria pe sibẹ. Ọmọ-ọba na sọrọ iwuri pupọ O ni inu on dun fun gbogbo ariya ti awọn ara ilu ti nṣe fun on, o ni on si

((Wo oju ewe ogbon)






Aworan yi ni awọn ero iworan ni gbangba ọdan ni ọjọ ikini oṣu yi, nigbati a ngba ominira ilẹ wa.

# Amẹrika ki Naijiria ku orire Ominira



Ọgbẹni Joseph Palmer



Ọlọla Nelson A. Rockefeller Gomina ilu New York, o jẹ asoju ti o wa fun ajọyọ ominira Naijiria

*Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"*





## Gbọn aisan awọ-ara rẹ nu łoru ọjọ kan



**Egbogi titun ti awọn sẹṣẹ fi ọgbọn ijinlẹ wari bẹrẹ si fi opin si awọn aisan ekuru, rọrẹ, lapalapa, ogodo, ekusa ati isaka-ṣaẹ loojọ—Onṣiṣẹ lẹ nigbati o ba sun.**

NIXODERM jẹ egbogi apoḥa [illegible]

[illegible]

**NIXODERM**

# ỌRỌ-OLOTU

## IBUKUN NI FUN OJU TI O RI EYI

IBUKUN nlanla ni fun ẹniti gbigba Ominira Ijọba Apapo Naijiria yi s'oju ẹmi re. Ọpọlọpọ ni awọn enia ti nwọn nreti ọjọ na sugbọn ti aseko na ko ṣe oju wọn. Awa ti a wa ni aiye ti asiko na si soju wa ti a si tun je alabapin ninu ayọ Ominira o ye ki a fi ọpẹ fun Olorun. Ki a si gbadura si Olọrun ki o tunbo fun wa ni emi-gigun ati alafia ara lati fi gbadura idera Ominira na.

Tani o mọ iyi Ominira? Bi a ba ti fi adie si inu aro fun ọjọ pipẹ, ti a ba si i sile, a fo jade peerepe, pe on nri ominira, bi obirin ba wa ninu oyun, ọjọ ti o ba bi ọmọ a yọ yọ pe on ri Ominira, eniti ijọba ba mu pelu awọn arufin, ti nwọn ba ye ọran ejọ tire wo, ti adajọ ba si da a sile kuro larin awọn arufin, a jade ninu kotu pelu ọpẹ pe "mo dupẹ! mo dupẹ!! mo dupẹ lọwọ Olorun!!! Beni eniti o ti wa ninu aisan fun ọjọ pipẹ, ọjọ ti o ba san, a mọ iyi Ominira, beni eru ti o ba ra ara tabi iwofa ti o bọ okun gbese kuro lorun ati be ẹ be e lọ titi.

Ọpọlọpọ awọn ti oye ku die fun, ti nwọn ko si ri iru adanwo ti a so si oke yi ri ko mọ iyi Ominira ti a gba, nitori ti Ominira na je ti gbogbo wa ni Naijiria ti ki i ṣe fun ẹnikan soso ti a da sile kuro ninu ipọnju, awọn miran tile nso pe kini anfani ti a le ri ninu Ominira yi ti a ko kuku jeki awọn oyinbo ma a jọba le wa lori nitori Enia-dudu ni ika ninu ju obo lọ. Nitootọ Enia-dudu ti o ni ika ju ọbọ lọ wa, sugbọn ki iwa ika wọn le de opin ni a ṣe gba Ominira yi.

Bi iwa ika, awọn osika yio se de opin ati bi Ominira yio ti se fa ire wọle fun gbogbo wa ti a o fi ni idera, owo ara wa ni a o fi fa a. Ohun ti a ni lati bere si se ni ki a mọ iṣẹ wa ni iṣe, ki a maṣe ṣe ole. Ki a maṣe fi ọkan si a ti ri owo ifa, a ti fi ọkan si owo ifa ni nomu elomiran di ole nibi ki o rira a kiri ile ibiti nwọn nta-tete kiri, bi o ba ta bi ko ba jẹ, a bere si i ma a jale, a di ogboju ọlọsa, dana-dana, gunbe-gunbe, agba dulumo, ajomogbe ati be e be e lọ.

Bi a ba tele inase bi awọn oyinbo ti o ko wa de aye Ominira ti nse nlo pelu ara wọn, a o gbadun Ominira ki a feran gbogbo ara wa bi ọmọ iya kanna, ki a maṣe dale ara wa ki a mase seru pelu ara wa, ki o si gbekele ara wa, nitori aisootọ ati aini-igbekele si ara eni je nataki arun buruku ti ko ti jeki Naijiria wa ni Ominira. "Adie da ni ni ogun nu a fo o levin" ati ife-ti-ara eni nikan, laika ife ilu eni si, gbogbo iwa aleebu wonyi ni lati parun, okunkun Ijoba Naijiria atijo ti o ti koja lọ, ki a si gbe aso imolẹ Ominira titun yi wọ.

Ki a ni ife ara wa laiya eya ilu kan sọtọ pe Hausa ni eyi, Ibo ni eyi, ki ise ara wa, iyen ko ṣiṣẹ ni inu Ominira ti a wa yi. Bi a ba ti so Apapọ Naijiria di ọkan ki gbogbo isesi wa si je ọkan, ki ero wa si sokan lati ma a lena ilosiwaju orile-ede. Ki o mase je kiki ngo ṣise de awọn ọmọ ki iya ma ba a le wọn lehin ola nikan ni a o ma lena nitori eyi ni o pọju ninu iwa Enia-dudu.

Yoruba ni "arise ni arika, arika ni baba iregun." Ọwọ ifẹ ati irẹpọ ti a ba fi lelẹ ninu Ominira yi ni awọn iran ti mbo yio tele ti nwọn yio si fi ma a gbe orile-ede wa ga. Ki onikaluku ki o sa agbara re, ki a ma ka ara wa kun nko koku nṣe oselu, nko si nibẹ bi nwọn ba ti le se ki nwọn ki o ma a se nso." Bi o ko si ninu asoju Igbimọ ilu, ti o ko nṣe kansilọ, mu imoran ti o ba ri pe o tọ fun idagbasoke ilu wa ki a ba e fi sinu Iwe IROHIN YORUBA ki gbogbo araiye gbọ ohun rẹ.

Ibukun ni fun oju ti o ri eyi.

# Mo kan saara si Oloye Awolọwọ

INU mi yio dun bi Olotu Iwe IROHIN YORUBA ba le gba mi laye lati kan saara si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria fun ọrọ iṣipade ti o fi ṣi ipade Ajọdun keje ti a ṣe l'Eko ni aipẹ yi.

Gẹgẹbi mo ti jẹ ọkan ninu awọn Ikọ ti o wa si ipade na, ẹtọ mi ni pe ki nfi ye gbogbo awọn enia pe laakaye ati imọ iṣelu Oloye Awolọwọ tubọ nga lọ siwaju si i ni. Eyi fihan daju gbangba pe Oloye Awolọwọ ni o le ṣe aṣiwaju oṣelu Apapọ Ijọba Naijiria fun idagbasọke ilu ju ti awọn aṣiwaju Ẹgbẹ oṣelu miran lọ, ti a ba nfẹ ẹkun-rẹrẹ alafia ati idẹra Ominira Ijọba ti a gba yi.

Mo si tun kan saara si Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati 'Gbakeji Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre fun ọgbọn ati oye ti o fi nṣe eto iṣelu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, omi ko yatọ si ọti ni iṣẹ iṣelu on pẹlu Alakoso Ijọba Iwọ-Orun takọkọ.

Emi ni,

**Prince Y. Ade Atiba.**
Ibadan.



Aworan yi ni igba ti Ọmọ-ọba Alexandra ngbọwọ lọwọ Ẹni-ọwọ-julọ A. W. Howells, Biṣọbu Anglican l'Eko, lẹhinti nwọn ti ṣe isin tan ni Cathederal Church l'Eko ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi



# Ọwa Ilesha di alakoso Igbimọ awọn Ijoye Ipinlẹ Iwọ-Orun

NINU ipade Igbimọ awọn Ijoye Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn ṣe ni Ibadan ni ọjọ 'Rú ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja yi Ọba Alaiyeluwa Biladu Keji Ọwa Ilesha ni nwọn mu ni alakoso Igbimọ na, nwọn si fi Ọba Alaiyeluwa Ẹwi Ado Aladesanmi Keji ṣe Igbakeji Alaga.

Ni ọjọ ipade na ku ọla ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti ṣe ikede pe awọn Ijoye mẹrin tuntun ti di mẹmba Igbimọ awọn Ijoye Ipinlẹ Iwọ-Orun. Awọn na ni: Oloye Dọkita Akinọla Maja, Jagunmolu Ijaiye. Oloye Rotimi Williams, Apesin Itoko, Abẹokuta. Alhaji S. O. Gbadamọsi, Ọtun Ikorodu ati Ọba Alaiyeluwa Samuel Akinsanya, Ọdẹmọ Iṣara.


Ọlọla Adesoji Aderẹmi, Ọni Ifẹ, Gomina, Ipinlẹ Iwọ Orun

Ninu ipade ti Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ kanna ti Igbimọ awọn Ijoye pade, Ọmọ-ọba Adeleke Adedoyin ni nwọn tun yan ni Alaga Igbimọ na. Ọgbẹni T. L. Adelẹgan aṣoju iha ariwa Ilesha ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni nwọn yan ni Igbakeji Alaga.

Aworan oju ewe yi ni ti awọn Ọba ti nwọn jẹ mẹmba Igbimọ awọn Ijoye na gẹgẹbi ẹtọ wọn. Alaiyeluwa Ọni Ifẹ ni Alakoso Igbimọ na ki o to di Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun.


ALAFIN


ỌWA BABA EGBE


ALAKE


AWUJALE


AKENZUA


OLU WARRI


OLOWO


OLUBADAN


AKARIGBO


KO SI ENITI O BỌ LỌWỌ

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro
Jẹ ki o gbe koro
"ASPRO" mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# Ọmọ-Ọba Alexandra ba Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun sọrọ lori ẹrọ isọrọ sokere



OLOLAJULA Ọmọ-ọba Alexandra si Ile-ẹrọ Isọrọ-sokere Posu ofisi Nla ni Opopo Ehingbẹti ni agogo mẹsan koja iṣẹju mẹdogun ni arọ ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kejidilọgbọn oṣu ti go mẹsan koja iṣẹju mẹdotitun na sọrọ si Ọlọla Ọba Adesoji Aderẹmi, Ọni Ifẹ, Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni Ibadan.

Wọnyi ni ọrọ ti Ọlọlajulọ Ọmọ-ọba Alexandra ati Gomina na fi ẹrọ titun na ba ara wọn sọ larin Eko ati Ibadan.

GOMINA—Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ni o wa nihin.
ỌMỌ-ỌBA—Ẹ ku owurọ o
GOMINA—Ku-owurọ o, Iyaafin Ọlọla Ọmọ-ọba, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi lati ba nyin sọrọ.
ỌMỌ-ỌBA—O dun mọ mi pupọ lati ṣe bẹ ẹ

Aworan yi ti igbati Ọmọ-Ọba na mba Gomina sọrọ.





Aworan oke yi ni ti awọn Ọlọkọ Ajẹ ti nwọn ṣere ni Ebute Ehingbẹti ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi fun ti ajọyọ Ominira.

* * *



Aworan oke yi ni igbati Ọmọ-ọba Alexandra de si Eko ti Ọgbẹni Bovell nki Ọmọ-ọmọ na ku-abọ.

# Ọkunrin kan ṣubu lulẹ, o si ku si ita gbangba

OSHODI.

**Bi giripa ọkunrin kan ti nrin rekọja lọ ni opopo ode Brown, (Brown Street)** t'o si rin de iwaju ojude ile **Ọgbẹni Brown na ni Tesan** Oshodi ni deede agogo marun owurọ ọjọ Eti ti ṣe **ọjọ kẹrindilogun oṣu yi ni o ba digbolulẹ lojuji ti ko si le da dide mọ.**

Lẹsẹkẹsẹ na ni gbogbo awọn ero ona ati aladugbo bu figbeta, okiki si kan yi ka gbogbo adugbo ti gbogbo enia pe le e lori.

Bi awọn Olopa ti gbọ irohin na ni nwọn ba sare wa sibẹ, nwọn yiri rẹ wo, nwọn si ri i pe o ti ku, nwọn tu ara rẹ wo, nwọn ba owo pọnun mẹta ati nain (£3. 9. 9d) pelu kọkọrọ ile rẹ n'apo rẹ ti nwọn wadi orukọ rẹ lọwọ awọn ti o duro nibẹ ṣugbọn ko si ẹnikan o mọ ọ rara, ni awọn Ọlọpa ba gbe oku rẹ lọ si Teṣan Ọlọpa ki nwọn to tibẹ gbe e lọ si Lakulaku Ile-iwosan fun ayẹwo iwadi iku rẹ.

Awọn Ọlọpa si wa lẹnu ọ̀ńtoto iwadi ohun ti o ṣekupa ọkunrin na.

Oluwa rere gba wa lọwọ iku akọṣẹku o.


Jan

LAKUREGBE!

ni kumọ nla kan



Mase jẹ irora lakuregbe lo yiri mo. Lo ALGESAL ki o si gbon irora na danu. ALGESAL jẹ ikan ni o ni Diisilat-asese'ari isanu apọrọ idi lulyi fun iwosan atorunwa ti yio wo inu ara de isale dada o si ohun ti o le di ALGESAL lowo. Ara alwu ati ara gigan yio lọ o bọ lowo irora ayanilara. Inu re yio dun pe o ti lo egbogi ipara ALGESAL BALM.

Ra apo re kan loni.

Ogbon tinla ti nwon fi dan ALGESAL wo ti fihan pe o nwọ ara tinle ni igba meta o nyara sise ni igba meta ju awon egbogi ipara miran lo.

ALGESAL

ipara pe iwosan ni igbe meta

NIGERIAN EXHIBITION October 1st-22nd STAND 168

Gbogbo awon onile elegbara gbodo lo ALGESAL.

O tun wa fun iwosan Lakuregbe, Aituka, Pulapala, Alsan-Wodi-Wodi, Lakuregbe-Ibadi, Lakuregbe Wonwonse, Aragiga, Lakuregbe-Arungun, Oturu agbari.



# ITAN EKO (2)

## (Lati ọwọ Alhadji Y. A. Disu)

OBINRIN kan mbẹ ni Iddo laseko itan yi, oruko rẹ a ma a jẹ Aina. O ni owo pupọ, ola rẹ poju ti gbogbo obirin ẹlẹgbẹ rẹ lọ.

Awọn ara igbaani mba a jẹ, nwọn ni o ni ẹiyẹ aje, nwọn si taku pe ki o ga fi ilu silẹ fun wọn. Nigbati nwọn si wa lẹnu ọran yi ni awọn enia Ọlọfin pa ewurẹ kan ninu awọn ẹran ọsin obinrin na.

Obirin yi dide lọ sọ fun Ọlọfin ohun ti awọn enia rẹ ṣe si i. Ọlọfin si fi esi pe, "bi awọn enia mi ba pa ẹran rẹ nkọ, kini o le ṣe?" Obirin na si fi ibinu fi Iddo silẹ lọ ilu Ọba Ibini. O sọ irọhin gbogbo ohun ti o ṣẹlẹ yi fun Onibini, nigbati o de ọdọ rẹ.

### ONIBINI BERE OGUN

Ọpọlọpọ igba ni Onibini nran awọn ọmọ ogun rẹ lọ si Iddo pẹlu awọn Balogun rẹ mẹtẹta, Aṣeru, Akigbida ati Ọlọrunghiwa lati kọya fun Aina. Ọlọfin ati enia rẹ si ni o nṣegun.

Nikẹhin ni "Ayaba" Ọlọfin ti a npe ni Ajaye da Ọlọfin ati Iddo. O gbe ibọdi awọn ara Ibini nipa fifi idi agbara ọkọ rẹ han awọn ọmọ-ogun Onibini. O gba oogun'baje lọwọ awọn ọta ilu rẹ, o si da a sinu gbogbo oogun ti ọkọ rẹ fi nṣe agbara jagun.

Iṣi ti obirin na fi dalẹ ni pe, awọn ọmọ-ogun Ibini tan a nje pe, ti o ba ran awọn lọwọ ṣẹgun, awọn yio fun un ni ọpọlọpọ ilẹkẹ iyun.

### OGUN MU ỌLỌFIN

Nigbati nwọn si ṣẹgun ara Iddo tan, awọn ọmọ-ogun Onibini mu Ọlọfin lọ si ọdọ Ọba wọn, ṣugbọn Onibini ko pa Ọlọfin. O paṣẹ pe ki nwọn fi i sinu ile kan ti ko ni oju ti ogiri rẹ si ga pupọ, ki ebi le le p an ku si ile na.

Lẹsẹkẹsẹ, nwọn mu aṣẹ Ọba na ṣẹ. Ṣugbọn nkan-kan ko ṣe Ọlọfin f'ọpọlọpọ ọjọ ti o wa ninu ile yi. Kanran ki Ọlọfin ku, okiki ariwo ọja ni awọn ara ilu ngbọ lati inu ile na wa. Nwọn si lọ sọ ohun iyanu yi fun Ọba, on na wa si itosi ile na, o fi eti ara rẹ gbọ okiki ati ariwo na.

Nigbati Ọba Ibini wọ ile na ti o si fi oju ara rẹ paapa ri i pe Ọlọfin ko ku, o pe e ni enigmọ, o si da a silẹ. Ki Ọlọfin to pada wa si Iddo ni olobo ti ta a pe Ajaye obinrin rẹ ni o ṣe lọẹ ibi na ti ọwọ ọmọ-ogun Ibini fi le tẹ on, o si bẹ Ajaye lori nigbati o pada de Iddo.



ALHADJI Y. A. DISU

* * *

Ajaye ko ku, akeku rẹ si nrin kakiri gẹgẹ bi ẹnipe ori rẹ mbẹ l'orun rẹ, gbogbo enia si fẹran lati ma a lọ wo o pẹlu iyanu. Ọkan ninu awọn ọrẹ Ọlọfin ti a npe ni Aluworo tabi Olawẹn wa ki Ọlọfin ku abọ ọjọ, ni ọjọ kan o si ri akekubọ Ajaye ti o nrin kiri leti ebute.

O ṣe abere nipa rẹ, nwọn si sọ fun un bi o ti ṣe ri bẹ ẹ. Oluwẹn fi agbara oogun rẹ paṣẹ fun akekubọ Ajaye pe, ki o wọ omi lọ; lẹsẹkẹsẹ o si wọ omi lọ.

Lati ọjọ na lọ ni a ti npe ibu omi jinjin ti Ajaye wọ lọ ni "Ibu-omi Ajaye". Bi ẹnikẹni yio ba si bura ni Iddo, a ma a wipe, "bi mo ba ṣe nkan na, ninu Ibu omi Ajaye ni ki nku si". O ti di ohun ibura.

Ọkunrin alagbẹdẹ kan ti a npe ni Ogunjasa mbẹ ni Iddo lakoko na. Nigbati awọn Ibini mu Ọlọfin ni igbekun lọ si Ibini, inu rẹ bajẹ pupọ ju, o bajẹ gidigidi tobẹ ẹ gẹẹ ti oti wọ omi lọ. Nitorina ni nwọn ti fi ṣegun ni Iddo pe, ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe agbẹdẹ nibẹ mọ. Agbami ti o binu wọ lọ ni a npe ni "Agbami-Ogunjasa" Nigbati aiye di aiye Gẹẹsi ni nwọn bẹrẹsi kọle arọ si Iddo.

Ọlọfin gbe Iddo fun ọpọlọpọ ọdun titi ọjọ ti o wọ inu ibu-omi aya rẹ, Ajaye lọ. Awọn ẹni mẹtẹta ti a daruko ti a si sọ itan wọn yi jẹ awọn enia nla laseko tiwọn ni Iddo, tobẹẹ gẹẹ lẹhin iku wọn, bibọ ni ọpọlọpọ awọn enia mbọ wọn bi oriṣa, awọn si ti di irunmalẹ si Iddo.

### ỌBA IBINI DA AṢERU LỌLA

Lẹhin iṣẹgun awọn ara Ibini lori awọn ara Iddo, akọni Balogun ti a npe ni Aṣeru, ọkan ninu awọn ara Ibini a ma a gbogun lọ si ilu Awori, a si ma a ṣegun wọn. O ni igboiya o si ni ọmọ-ogun pupọ. O jagun molu titi de ilu Iṣẹri, nibẹ ni o ku si.

Awọn ara Iṣẹri ko jẹ sin oku rẹ si ilu wọn; nitoripe iranṣẹ nla ti Ọba Ibini ni iṣe. Aṣipa si gb'oku Aṣẹru lọ si Ibini. Inu Onibini dun si Aṣipa pupọ fun ohun ti

(Wo oju ewe kẹdọgbọn)

Itan Ti Julius Sọ Lori Ọti Waini Ti O Nfunni Ni Ilera

Ẹ Ka nkan ti ọti Atẹjẹṣe PHOSFERINE TONIC WINE ṣe fun Julius Ajayi ti ongbe, 3, Akintoye Street, Yaba, Lagos.



Lọ Si Sọbu Ibiti O Ti Nra Ọja Kiakia ki O Si Ra Ọti Waini Atẹjẹṣẹ, PHOSFERINE TONIC WINE Fun Ara Rẹ

"Famous Fortunes"

# "Iwa biti-biti ko jẹ ki Ẹgbẹ onișowo Ipinlẹ Ila Orun ni ilọsiwaju"

ENUGU.

NINU ipade ajodun karun ti Apapọ Ẹgbẹ Ajumọșepọ Onișowo Ipinlẹ Ila-Orun (Eastern Nigeria Cooperative Congress) șe ni ilu Enugu laipẹ yi, Oloye J. U. Nwodo, Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Aje Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun sọ fun ipade na pe, aimeto iṣẹ aje, iwa bitibiti ati aisotitọ nipa ọran owo ni o mu ifasẹhin ati ainilọsiwaju ba ẹgbẹ na, o sọ rọ gbogbo ẹgbẹ na pe ki nwọn parapọ fi ọwọ-sowo wo arun aisotitọ na san.

Minista na si șe alaye pe, lotitọ, Ijọba ka Ẹgbẹ Onișowo na si pataki, o si fẹ șe iranlọwọ diẹ fun un, șugbọn idagbasoke ati ilọsiwaju ẹgbẹ na ku si ọwọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na.

Ọgbẹni D. E. Ebe, Olori ẹgbẹ na sọ ninu ọrọ rẹ pe, ẹgbẹ na ti nșe eto ilọsiwaju pataki fun ẹkọ ati Eto Ikede Irohin ẹgbẹ na pẹlu. O tun sọ fun awọn Ikọ ti o wa si ipade na pẹlu pe awọn ẹgbẹ t'on ti fi ọgọrun pọnun (£100) ranșẹ s'awọn ẹlẹgbẹ wọn ti o wa ni ilu "Chile" nibiti iṣẹlẹ nla kan gbe șelẹ laipẹ yi, o si tun sọ fun wọn pe, Adapọ Ajumọșepọ Ẹgbẹ Onișowo awọn orilẹ -ede (International Co-operative Alliance) ti fi Ẹrọ-itẹwe kan ta ẹgbẹ awọn lorẹ.

## Așoju Ijọba Amẹrika ki Naijiria ku orire

OGBẸNI John K. Emmerson, Așoju Ijọba Amẹrika ni Naijiria ba awọn ọmọ Ẹgbẹ Akẹkọ ilu Amẹrika sọ ọrọ iwuri ni Ẹnugu ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹwa oșu ti o kọja yi nipa eto iranlọwọ ti Amẹrika nșe fun ilọsiwaju ilu Naijiria.

Ninu akọsọ ọrọ rẹ Ọgbẹni Emmerson ki Naijiria ku orire ti Ominira ilu na, o ni on fi t'ọkan t'ọkan ba gbogbo awọn ara ilu na yọ.



JOHN K. EMMERSON

* * *

Ọgbẹni Emmerson si șe alaye nipa itan ati igbesi-aiye ọmọ enia ati bi ẹkọ ti jẹ pataki fun ọmọ enia. O ni aini ẹkọ i ma a mu enia șișe ni. O ni on ni ero pe, awọn ọmọ Naijiria ti o lọ kọ ẹkọ ni Amẹrika ni ẹtọ lati șe igberaga nipa ẹkọ ti nwọn ni nibẹ.

Ọgbẹni Emmerson sọ pe ninu ọdun 1636 ni nwọn da "Harvard College" ti orukọ rẹ kakiri aiye, silẹ ni ilu Amẹrika ati pe ninu ọdun 1647 ni ilu Massachusetts ni nwọn kọkọ șe eto ọna bi nwọn yio ti șe ma a kọ awọn enia ni iwe dada. O si ni inu on dun lati ri i pe Amẹrika șe iranlọwọ gan an nipa ile iwe giga-julọ ti nwọn kọ si Nsukka ni Naijiria.

Ọgbẹni Emmerson na tun fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ yi pe awọn ara Amẹrika ti se tan lati ran Naijiria lọwọ dada ninu ohun ọgbin, bi nwọn ti șe sișẹ ọgbin dada de aye ti nwọn yio ma a fi hu pupọ.

O ni awọn ara Amẹrika mẹtala ti nwọn ni imọ ijinlẹ nipa iṣẹ ọgbin ni nwọn ti de si Naijiria ati pe awọn mẹwa miran si tun mbọ wa si Naijiria fun iranlọwọ nipa iṣẹ na. O ni awọn ti nwọn ti de ti bẹrẹsi șișẹ ọgbin na nwọn si ti nfi ọna ti nwọn fi șe e han awọn ara Naijiria ti nwọn wa lẹnu iṣẹ na ati awọn ti nwọn nkọ ọ lọwọlọwọyi.

Ọgbẹni Emmerson șe alaye ninu ọrọ rẹ pe o ti to ọgọrun awọn ara Naijiria ti awọn ara Amẹrika ti kọ ni iṣẹ ọgbin ni akọyọri. Ni ipari ọrọ rẹ, o ni inu awọn ara Amẹrika ati Ijọba Amẹrika dun si Ominira Ijọba Naijiria gidigidi nitoripe ẹtọ wọn ni irufẹ Ijọba na. O si sọ pe yio dunmọ Amẹrika lati șe iranlọwọ ti o ba tọ si Naijiria ti o ba bere fun un ku orire.

## Adeșọkan jẹ oye Balẹ Ilobi

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejila oșu ti o kọja yi ni Ọba Alaiyeluwa I. B. Akinyẹle, Olubadan Ibadan fi Ọmọ-ọba Yesufu Ayilara Adeșọkan, ẹni ọgọta ọdun ọmọ Iba Oluyọle Ibadan jẹ oye Balẹ Olobi Oja'ba Ibadan rọpo Ologbe Oloye Raji Maganna ti o ku ni nkan oșu kefa sẹhin.

Oloye titun yi ni baba Ọgbẹni A. O. Adeșọkan ti o ti wa ninu awọn Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti ana ri. Ẹsẹ awọn Oloye ati gbajumọ ni o si pe sọsọ si ibi așeyẹ na, Oloye titun na ati awọn ọmọ rẹ si fi ijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabașeyẹ ọjọ na lọrun.

Oye a mọri o.



# OMINIRA ATI ISIN NI NAIJIRIA

"OMINIRA de wẹrẹ, o de? Orin ayọ aladun yi ni gbogbo awa Yoruba nkọ lati fi yọ ayọ ominira ti o tẹ ilu Naijiria lọwọ. 'Ayọ a bi ara tintin! Ayọ a yọ kalẹ' ni gbogbo wa ṣe adura pe ki o le ṣẹ si ilu wa.

Iṣe gbigba ominira yi ki i ma a ṣe iṣe jẹlẹnkẹ. Ẹni ma a gba ọmọ lọwọ ẹkuro yio ma mura dain-dain. Ẹni ma a ja ọmọ lẹhin ẹkun yio ma fi igboiya gbe iku ta.

Ki ominira to tẹ ni lọwọ, rẹrẹ run si ibẹ, iṣẹ gidi-gain ni ọpọlọpọ ara ilu aṣaaju ninu ogun fun ominira, atọkun ọna ominira ṣe ki o to di pe ominira na de. Awọn baba wa ni i ma a pa owe pe "Ẹni a ba pa agbọn lori rẹ ki i ma a duro jẹ ẹ".

Omiran ninu awọn jagun-jagun ominira yi ni nwọn ko ma a duro jẹ anfani ominira yi. A ki yio gbagbe wọn. Akọni enia ni wọn. Iṣẹ aṣeele wọn ni a si ngbadun loni.

Alagbara ni a pe awọn ti nwọn ṣe iṣẹ yi. Nibo ni agbara wọn ti wa? Iranlọwọ wo ni nwọn ri ninu iṣẹ wọn.




## Lati ọwọ Dọkita J.O. Lucas

Ko si ani-ani pe agbara ati ohun ti isin nfunni wa ninu ohun ti o jẹki nwọn le ṣe aṣe-yọri. Ohun ti nwọn ṣe lode, lọna iṣẹ ilu, ni a ma a nwo, ṣugbọn oju wa ma nfo agbara, iṣiri ati okun ti isin wa ma nfun ni.

### AGBARA ISIN

Nwọn ni: "Bi ko ba si li oju, ki i kan si aiya", "agbara ti inu ni i han lode." Bi ko ba si agbara ti inu li isin ngmu wa, ohun kan ko le ni ṣiṣe rara, paapa ti o ba jẹ nipa ogun jija.

Ko si ọmọ ogun ti o le fi inu ofifo ja, ko si alaiṣan ti o le gbe ida lọ si oju ija. Ẹsin ni i nfunni ni ohun ti a gboju le. Ẹsin ni nfunni ni agbara ti inu a si han lode, ti i so ni di akoni.

A dupẹ pe awa ni ilu Naijiria ki i ṣe ẹniti ko ni isin, ti ko mọ Ọlọrun.

Isin ibilẹ ni ọpọlọpọ agbegbe ni ilu wa jẹ isin iborişa. Ṣugbọn a ko gbọdọ sọ pe ko si agbara kankan ninu wọn. Ki a to mu awọn isin miran wọle, isin ibilẹ ni ko jẹ ki awọn enia dudu parẹ.

Wahala nla ni nwọn la koja. ogun owo ẹru ja wọn. Ijakadi larin oriṣiriṣi ẹya nkọ? Sibẹsibẹ nwọn da ilu nla silẹ, nwọn si ntẹle eto isin wọn gẹgẹ bi imọlẹ ti nwọn ni.

(Wọ oju ewe kẹtalelogun)

## ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# Ori lo mọṣẹ aṣela ẹni ( I )

OLOTU iwe "Irohin Yoruba", ajinde-ara yio ma a jẹ fun nyin o. Laiṣe ẹmi ọrọ ni gigun, ero wa ni wipe gbogbo ẹnyin onkawe wa ni yio ti ṣe akiyesi ẹṣin ọrọ wa gẹgẹbi akọle iwe wa ọsẹ yi bayi pe:

### ORI L'O MỌ'ṢẸ AṢELA ẸNI

Ni akoko kan, ni igba lailai, baba kan wa ti o jẹ ọlọla kan pataki ninu ilu rẹ, baba yi ki iṣe ọba tabi ijoye rara, ṣugbọn o jẹ enia nla kan larin ilu na



AKIBU ALARAPE

* * *

nitoripe o fẹrẹ ma si enikan ti o lowo to baba ti a nsọrọ rẹ yi.

Bakanna si wẹ, baba na tun ni ọpọlọpọ obinrin gẹgẹ bi iṣe awọn ẹni-atijọ. Bẹ ẹ na ni baba yi si tun bimọ pupọ bẹẹrẹ bẹ, ṣugbọn iyawo irẹ kan wa ti koi bimọ rara, o si fẹrẹ jẹwipe iyawo yi gan an ni baba na fẹran ju.

Atipe, iyawo yi gan an ni o si jẹ ọmọ kekere julọ ninu awọn iyawo yoku nitoripe gbogbo awọn iyawo yoku ni nwọn ti bimọ ti o ju iyawo kekere yi lọ lọkunrin ati lobirin, ṣugbọn sibẹsibẹ na, awọn iyawo ti nwọn jẹ alagba si iyawo kekere yi ko ni ifẹ si rara to bẹẹ ti ọkọ wọn ti o jẹ eni pataki fi ọmọ pe nwọn ko fẹran rẹ.

Bayi ni gbogbo nkan nlọ, ṣugbọn ni ojojumọ ko si nkan meji ti o jẹ ẹdun ọkan fun baba yi bikoṣepe ki iyawo kekere yi na sa bimọ 'nwọn si bẹrẹsi ṣe aajo titi, to bẹẹ ti baba yi paapa fi di alaini, ṣugbọn ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ baba na ni nwọn ti di olowo nitoripe lori wọn na ni owo baba yi fẹrẹ parẹ si tan patapata.

### IYAWO NI IRETI

Sugbọn sibẹsibẹ na iyawo kekere yi si wa pẹlu ọpọlọpọ ireti pẹlu baba yi, ṣugbọn nkan ti o ṣeni lanu ni wipe, gbogbo awọn iyawo baba yi ti awọn ọmọ wọn ti di enia nlanla ni nwọn kọ naani baba yi mọ, bẹ ẹ si ni, baba yi ti di alaini patapata.

Ero awọn iyawo wọnyi nigbana ni wipe, bi awọn ba tete ṣe iranlọwọ kan fun baba yi nipa owo nṣe ni on pẹlu iyawo rẹ kekere yio jijọ na owo na. Nitori bẹ ẹ, gbogbo wọn kuku pa baba yi pẹlu iyawo rẹ ti si apakan, nwọn kọ si ka wọn kun mọ rara.

Bayi ni gbogbo nkan na bẹrẹsi lọ titi ti o fi di ọjọ kan. Ẹ ma gbagbe wipe, ẹṣin ọrọ wa na gẹgẹbi akọle oke itan yi ni wipe, "Ori l'o mọ'ṣẹ aṣela ẹni"

Bi ilẹ ti mọ gbara ni owurọ ọjọ ti a nwi yi, bẹni alagba kan wọle de, o si ki baba yi daradara, lori ibiti nwọn gbe ti nki ara wọn yi ni baba na ti ṣe akiyesi pe, ọrẹ on atijọ ni alagba na nṣe, nwọn si ki ara wọn dada. Alagba na si jẹ ogbologbo babalawo. Lẹhin ti nwọn ki ara wọn tan ni baba yi wa fi ọrọ iyawo rẹ kekere yi siwaju alagba yi nipa airọmọbi rẹ. Nwọn sa ti sọ wipe: "Ohun ti o ba ndunni ni a njafun mu loju ogun.

### NWỌN D'IFA

Lẹsẹkẹsẹ na ni babalawo yi fa ọpọn Ifa rẹ yo ninu apo, o si difa na fun baba yi, o si sọ fun baba na, wipe "iyawo rẹ yi yio bimọ ọkunrin kan laipẹ yi, atipe, ọmọ na yio si j'ọba laiye yi, atipe gbogbo aiye yi ni yio si pesin ọmọ na". Babalawo na si pari ọrọ rẹ sibi wipe, "Pẹlu ogo Ọlọrun, loju gbogbo wa yi ni ọrọ na yio ṣe".

Gbogbo ọrọ ti babalawo na sọ yi jẹ iyalẹnu p upọ fun baba yi nitoripe ki iṣe ọmọ-ọba, atipe idile wọn kọ tilẹ nje ọba rara. Ju gbogbo rẹ lọ si wẹ, ko tilẹ si ọba ni ilu wọn rara nitoripe ọba kanṣoṣo ni o npaṣẹ gbogbo aiye ni igbana, ilu ibiti ọba na si wa si wọn jinna ju ẹgbẹrun ibusọ lọ.

Sibẹ na, inu baba yi dun pupọ lati gbọ gbogbo ọro asọtẹlẹ babalawo na.

(Wo oju ewe kejilelogun)




Njẹ o ti ri
AJAPA ALAWỌ-ALIGA RI BI ?



**O ṣẹṣẹ de si ile-itaja adugbo rẹ ni !**

Ajapa Alawọ-Aliga ni ẹni ayanfẹ ti o le ri lara gbogbo awọn Panu-onjẹ ti Ile-Iṣẹ Alumaco titun ṣe ni Apapa. On ni o joko lori awọn ikoko-irin-afuyẹ ati awọn panu ti o ndan yanranyanran ti o si nwoye pẹlu ifaiyabalẹ si ara rẹ nibẹ yi. O le jẹwipe bi o ti wi ni o ri—awọn ikoko ati panu rẹ ni o darajulọ ti o le ra—wọn lagbara to bẹ ẹ gẹ ẹ, nwọn ko le faya tabi ki nwọn dipẹta. Nwọn tun dinwo pẹlu nitoripe nwọn ni alopẹ pupọ ju iru awọn awo-onjẹ miran lọ. Ma a fi oju wa Ajapa Alawọ-Aliga ni Ile-Itaja adugbo rẹ.

AWỌN AJAPA ALAWỌ-ALIGA jẹ ayanfẹ pataki ninu gbogbo awọn Ile-idana igba isisiyi,

ẸNYIN ONIṢOWO
Bi ẹ ko ba ti i ra awọn Ajapa Alawọ-Aliga sinu ṣọbu nyin—ẹ tete wa ri wa kiakia.

Awọn ti o nṣe nikan ni

**ALUMACO**, P.O. Box 60, Apapa, Lagos,
Telephone: — 55715


Surf
VIM
Pepsodent
Asepso
Awa ṣe
alabapin ninu
aṣeyọri Ominira Naijiria
HAZLEHURST & SONS (W.A.) LTD.
SALES PROMOTION AGENTS FUN
UNILEVER EXPORT LIMITED
Awa si nfoju-sọna lati jẹ alabapin
ninu idẹra Naijiria fun igba ti o mbọ...
lati tun jẹ oluranlọwọ ninu akojọ
ọrọ Naijiria ni ọpọlọpọ ọdun ti o mbọ
Rexona
LUX

# Ọmọ-ọba Alexandra de si Ipinlẹ Iwọ-Orun





Aworan oke yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Adeleke Adedoyin, Alaga Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nki Ọmọ-ọba Alexandra ni Ebute ọkọ ofurufu ni Ibadan. Ọlọla-julọ Adesọji Aderẹmi, Gomina Ipinlẹ Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Odun ni nwọn duro lẹgbẹ Ọmọ-ọba na.

Aworan oke yi ni ti igbati Oloye Akintọla nki Ọmọ-ọba na.

# Dare ṣe ikomọ alarinrin

ILỌRIN.

OGBẸNI J. O. Dare, Alabojuto Ile-iṣẹ "Dare Patent Medicine Stores", Ilọrin ko ọmọ obirin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ lọrẹ laipẹ yi nwọn si sọ ọmọ na ni Oluwatoyin.

Esẹ awọn gbajumọ ati gbogbo awọn ọmọ Ijebu Ijẹsha ti o wa ni Ilọrin ati agbegbe rẹ ni o pe ṣọṣọ si ibi apejẹ alarinrin ti baba ọmọ na pe ni ọjọ ikomọ na.

Diẹ ninu awọn enia gidi ti o wa si ibi aṣeyẹ na ni awọn Ọgbẹni Sunday Owoso ati Agunlẹhinju, iyawo rẹ, Tom Famudimu, S. Owoeyẹ ati Sanni Ajimati. Ki Oluwa da ọmọ na si.


**Bata**

**SHOE CO. NIGERIA LTD.**

KI AWỌN IJỌBA ATI AWỌN ENIA APAPỌ NAIJIRIA KU-ORIRE GBIGBA OMINIRA IJỌBA NI ỌJỌ KINI OṢU KẸWA ỌDUN YI.

Awọn oluṣe ati olura ti o nra bata lati Ilu Oyinbo wa ti o si tun nfi rọba tutu ranṣẹ si ilu Oyinbo.

**Bata** SHOEMAKERS TO THE WORLD

Olu Ile – Iṣẹ, 81-87, Broad Street, l'Eko

Awọn Ẹka Ile - Iṣẹ wa yika gbogbo Naijiria.

# Ayọrisi idije orire Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

AWỌN enia ti o jẹ owo gbọi ninu idije ori're ti Ijọba Iwọ-Orun ṣe ni ọgbọn ẹlọ oṣu ti o kọja yi ni Gbọngan "District Council School" Ikẹja ni Iyaafin Rabi Adunni ti 3/19, Mission Street, Ibadan ni o ṣe orire jẹ ẹbun kini ti owo rẹ jẹ £3,000. Eniti o ṣe orire jẹ ẹbun keji £2,000 ni Ọgbẹni Paul Moses Newton ti 10, Montgomery Road Yaba, Lagos. Eniti o ṣe orire jẹ ẹbun kẹta £1,000 ni Ọgbẹni Joseph Ese ti 60 Mission Road, Benin-City.

Awọn ẹnikọọkan ti o ṣe orire jẹ £25

Isafah Oladebo c/o Oba Adedamola Imo Post Office Abeokuta; S O Abaduyamo Agbole Lakiri Oke Toko c/o J O Ogunbiyi Box 7 Ake Abeokuta; Falilatu Ajoke Igbore c/o34 Igbore Road Abeokuta; Lasisi Baba Sulifa c/o Yekini 24 Totoro Road Erunmu Abeokuta; Kofo Fasetn c/o P O Box 129 Ile Ife; Sotunde Okanlawon 33 Oodo Street East Ebute Metta; Dorcas Oduwole c/o Mr Oduwole Government House Lagos; T Limson—Olwa 32 Bishop Street Lagos; Abiola Omole No. 17 Brickfield Road Ebute Metta;

Adenuga Ogundowo G.B. Ollivant Ringim via Kano; Sanusi Akande 2 Daniel Street Idi Oro; Alfre Durodola 48 Kosoko St. Lagos; Rasidi Ojebe Ogbo Alufa c/o Aiyesan via Okitipupa; Olaiya Awonyi 132 Seluwe Layi Odi Olowo Mushin; Komuoshu Orizanu c/o Mr. Samuel Pirawe Pirawe Camp Mahin via Okitipupa; A O Oyenusi Agric. Exit Serv. Div. Ado Ekiti; James Alamu Catering Office University College Ibadan; Ayan Ripera 1 Adam Street Lagos; D Adegoke c/o I. K Adeyemi P O Box 39 Agege; and Nihinlola Abaka Anglican School Idiama Eaba Division.

Awọn ẹnikọọkan ti o ṣe orire jẹ £10

Edward Okpowoo, 28, Robert Road, Warri, Idiatu Afolabi, c/c A. O. Ganiyi, GBO Ltd. Jos; Fehintola Omotosho, Ilushin Estate Ltd. Ilushin, Ijebu; Sifawu Lawal, Ile Iyalaje, c/o Postal Agency, Lalupon, via Ibadan; Solomon Adegoke, United School, Ajegunle, Otta; Adedeji Oluwole, Ile Onibule Comp. No. 21, Kolawole St. Oshogbo; Grace Adeleye, Baptist Day School, Edunabon; Ife Olu Omotosho Box 373, Ibadan; Tokunbo Animashaun, Ansar-Ud-Deen, Ikeji Ogbomosho; Mrs. E. A. David Bethel African School Odopetu Box 116 Ijebu-Ode Hasard Oseni WAPCC Ikeja; Adeleke Adeosun 13 Kadisi Street Ijebu Road Mushin; Jonathan Hughes 14 Jebba Street East Ebute-Metta Lagos; Ayisatu Anike Ile Are Ago Olumole Akesan Market Oyo; Alice Omotayo Awele Obele-Odan Suru-Lere Lagos; Oyewole Samuel c/o Samuel Alabi Health Office Ilorin; E. S. King 6. Oke-Olowogbowo St. Lagos; N. Tamaklee Federal Ministry of Health Broad St. Lagos; Mr. Gabriel Otebata Railway Station Oshogbo; Agboola Ojo P and T Automatic Exchange Ibadan; Adedotun Afikuyomi 50, Old Yaba Road Yaba Lagos; Fatayi Atanda High Court Ibadan; C Igwe Box 43 Ibadan; Bavdiru Lawal 3, Itoko Road Post Office Ariliese Abeokuta; Folabomi Olabisi 32, Lewis Street Lagos; Sariyu Kayewumi c/o Banni Kayewumi 32, Aarderu Street Japara Ijebu-Igbo; Olafunji Oguns Box 60 Sagamu; Ladunl Ikuniká Local Government Police Station Ebute-Irele via Okitipupa; Oluwasola Anike 15, Idasa Street Ilesha; and J. Ade Fosoto St. David's School Akure —

Ajibade Joseph, Oko Baba, Via Ilobi P A; Sunday Eweke, U. A. C. Uromi; Joseph Ike Ore-Odigbo Via Ondo; Komoru Abibu Olufunmilade 1 Igbo Buro Street Ijebu-Ode; Samus Alamu 83/442 Ile Osa Agbongbon Ibadan; Olabode Atanda Box 671 Ibadan; Agbene Gan Adegoke 16 Agbore St Ondo; Oseni Sanni Sherolu Street Ilishan Remo Via Shagamu; Akintunde Alagbe L A Dispensary Box 30 Oyo; J A Ogunseye U A C Store Ikirun; Malam Mohamed Sanusi Sanni c/o A A Deji U A C Yola; Taofiki Aremu Box 13 Ibadan; E O Ladoku, Customary Court Court Iseyin; T O Apanisile 46 Wo oju ewe kokandilogun

Ẹ ma a ka Iwe
IROHIN YORUBA
nigbagbogbo fun
irohin aladun



# Gomina - Agba fun Bamgboye ni Mẹdali

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni Ọlọla James Robertson Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria fun Ọgbẹni Moses Bamgboye ni Mẹdali fun iṣẹ aṣeyọri ti o ṣe ni Abẹ Ijọba fun odidi ọdun mejidinlogoji (38 years) ti o si ṣe iṣẹ na yori laini aleebu kan titi o fi gba isimi lẹnu iṣẹ patapata.

Ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu kini ọdun 1922 ti iṣe ọdun kejidinlogoji sẹhin ni Ọgbẹni Moses Bamgboye bẹrẹ si ṣe ọmọ-ẹkọṣẹ iṣẹ lẹntiriki (Apprentice Electrician) labẹ oṣiṣẹ Ijọba ti ngmoju to iṣu (Public Works Department) o kọ iṣẹ na, o si yege, o si gba iwe-Ẹri yiyege na ni ọjọ kẹwa oṣu kini ọdun 1925 ninu eyiti nwọn sọrọ rẹ si pe o fi ara balẹ k'ọṣẹ, o si mọ iṣẹ na daradara ati pe o si tun ni iwa itẹriba pupọ.

Lẹhinna ni o bẹrẹ si i ba wọn ṣiṣẹ gẹgẹ bi oṣiṣẹ (journey-man) nigbati o si ṣiṣẹ na titi ọdun 1958, a gbe ipo rẹ ga si aye ọga agba (foreman of works) ni ọjọ kini oṣu kẹrin ọdun kanlelọgbọn oṣu kejila na. Nigbati o si di ọjọ kọọdun 1959 ni Ijọba fun un ni aye isimi (pension) pe ki o lọ fi ẹhin ti silẹ laiṣe iṣẹ mọ, ki o si ma a gbowo ifẹhinti na titi di ọjọ iku.

Ọgbẹni Bamgboye yi jẹ ọmọ Ẹgba Obagura, ti iṣe aburo Oloye Adekunjọ Bamgboye, Sarumi Oje ati Ntabo Kemta, ni Oko Ṣokori, Agọ Owu, Abẹokuta.

## Adebayọ Johnson bẹ Olotu wo

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni Ọgbẹni Ọlọta Adebayọ Johnson ti iṣe aṣoju Iwe "Irohin Yoruba" ni ilu Treichvill Abidjan Cote de Ivoire wa ṣe ibẹwo Olotu Iwe "Irohin Yoruba". Nitori ni a ti igba ti o ti nṣe aṣoju iwe na ko i ti ri Olotu ni ojukoju, eyi ni o mu u wipe on a wa fi oju kan Olotu.

Pataki ohun ti o wa ṣe ni Eko ni pe o wa ra ọja, nitori oniṣowo pataki ni, ni ilu ti o ti wa. On pẹlu Olotu si fi ọrọ jomitoro ọrọ pupọ ki o to ma a lọ. Ọjọ kẹta ti o wa ri Olotu ni o pada lọ si ibiṣẹ iṣowo rẹ.

Alọ adara o, ọkọ arefo o.






Ẹ ma a ka Iwe
IROHIN YORUBA
nigbagbogbo fun
Irohin aladun

# Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ipade ni Iddo

IDDO LẸBA IBADAN.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ipade ni Iddo lẹba Ibadan. Ọlọla A. M. A. Akinloye ni ọ ṣe alaga ipade na, ẹniti o kọkọ sọrọ ni Kansilọ Salawu Iyanda. O ni inu on dun lati ri pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o tun wa lori aga Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nisisiyi.

O ni on mọ dajudaju pe nwọn ki i ṣe adagba-male ṣe, nitori idi eyi, nwọn yio tẹ awọn ara ilu lọrun nipa ọna titi ṣiṣe, Ile-iwosan kikọ ati awọn nkan miran ti yio mu anfani wa fun ilu.

Awọn Ọgbẹni mejeji yi, Lawani Onikede ati Lamidi Bogunhunbẹ sọrọ pẹlu lori alaye rere ti Ọlọla Akinloye ṣe nipa Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni awọn paapa gunle.

Ọlọla Balẹ Buraimọ Langbin ti iṣe Alaga Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ikilọ fun awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o pejọ si ibi ipade na pe, ẹnikẹni ninu wọn ko gbọdọ fi ẹnikeji ṣe ẹfẹ nitoripe ifi enia ṣe ẹlẹya ma a ngmu ede aiyede wa. Ẹnikẹni ti o ba si lodi si amoran yi Ijọba yio jẹ ẹ ni iya.

Alaga na si mu ipade na wa si opin lẹhin ọrọ ti o fi gba wọn ni iyanju. Ọbọgbo wọn tuka, nwọn si nyọnbo Awo! Awo!! Awo!!! lọ si ile wọn.

# AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọọ sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdale Yoruba. A o si tẹẹ 'ade fun antani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU



# Ọmọ-Ọba Alexandra bẹ awọn Ọmọ Ẹgbẹ Alagbelebu Pupa wo ni Agbala Gomina-Agba





AWỌN Ẹgbẹ Alagbelebu Pupa Kekere (Junior Red Cross) [illegible]



Awọn aworan wọnyi ti han gẹgẹbi ariya ọjọ na ti jẹ. Aworan oke patapata legbẹ osi ni ti igbati Ọmọ-Ọba Alexandra mbẹ awọn ọmọ ẹgbẹ na wo. Aworan oke patapata keji legbẹ ọtun ni ti igbati Ọmọ-ọba na mba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ lọkọọkan. Aworan isalẹ yi legbẹ osi ni igbati o nyẹ awọn ọmọ ẹgbẹ agba na wo, aworan ti ẹgbẹ osi ni igbati o nyẹ awọn olori ẹgbẹ na wo. Aworan ti oke yi ni ti igbati ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na nṣe alaye iṣẹ ti awọn nṣe fun Ọmọ-ọba na. Wo oju ewe kẹẹdọgbọn fun awọn aworan yoku.






To a new nation from an old friend...
Congratulations!
SLOAN'S LINIMENT
KILLS PAIN
SLOAN'S LINIMENT
LAMBERT CHEMICAL CO. LTD., AND ITS ASSOCIATED COMPANIES
WILLIAM R. WARNER & CO. LTD., AND RICHARD HUDNUT LTD.,
EASTLEIGH, HAMPSHIRE, ENGLAND

# Itan Iwe Irohin Yoruba

## Lati ọwọ S. M. Ademuyiwa

IWE "Irohin Yoruba" ti wa lati ọjọ pipẹ, agba rẹ si tayọ gbogbo awọn iwe irohin ti o njade ni aseko isisiyi ni Najiria. Lati igba ti o si ti njade ni o ti nfi imọlẹ ilafu han gbogbo awọn ti o ba nka a ti nwọn si ti nreti pe, ti Ọlọrun ba si wa bakanna, ireti ominira mbọ fun enia dada.

Ni ọdun 1859 ti iṣe ọdun kọkanlelaadọta sẹhin, ẹniti o da Iwe na silẹ ni Enikẹwọ Alufa Henry Townsend ni Abẹokuta, ojiṣẹ Ọlọrun yi ni Oyinbo akọkọ ti awọn Ẹgbẹ Onigbagbọ ilu Oyinbo kọkọ ran wa si Abẹokuta, ti o si fi idi Isin Ọlọrun Ijọ C.M.S. (Church Missionaries Society) sọlẹ ni Abẹokuta.

Awọn irohin ti o njade ninu Iwe na igbana ni ikede igbeyawo ati irohin igbeyawo, irohin ti Ijọ awọn enia Ọlọrun ti ngbe Ilọsiwaju si, eto eto Ile-iṣẹ Ọlọrun..., ipolowo ọja tita, irohin bi iṣẹ iṣowo ti nlọ si, iṣoro-owo owu-ẹtutu, bi o ti nta si, nitori iṣẹ owu-ẹtutu yi ni pataki iṣẹ-owo ti Oyinbo nra ni ni ilẹ wa, ati ọpọlọpọ ọrọ isiri nipa pipa owu-ẹru rẹ pẹlu awọn nkan pataki pataki miran.

Awọn ti nwọn ko si idi iṣẹ itẹwe na, nigbati nwọn da a silẹ ni awọn ti awọn onise-Ọlọrun ṣeṣe yi lọkan pada ti nwọn di onigbagbọ kuro ninu ẹsin iborisa, ki nwọn le mia a ri iṣẹ ṣe jẹun nitori awọn enia wọn ti ọkan wọn le ninu ẹsin iborisa a ma a korira wọn, nwọn ko si nje ki nwọn ri iṣẹ ṣe. Iye ti nwọn nta iwe na ni ọgọfa owo ẹyọ (120 cowries) ti o jẹ bi kọbọ kan (1d.) igbana, Iwe "Irohin Yoruba" ni nwọn si npe e ni igbana yatọ si Irohin ti a npe e nisisiyi.

Nigbati o di pe ọtẹ kan dide ni ọdun 1867 si awọn onigbagbọ, ti awọn Ologun ti nṣe Ijọba ilu Ẹgba nigbana fi le gbogbo awọn ọmọwe kuro ni Abẹokuta ti ogunlọgọ wọn fi wa fi'di mulẹ s'Eko ni Iwe Irohin Yoruba na ba fara bu ọtẹ yi ti ko fi le jade deede mọ titi ti o fi dake patapata.

Ọtẹ igbana ni nwọn npe ni "Ọtẹ-Ifọle" gbogbo awọn onigbagbọ ti o si ṣi idi wa si Eko nigbana do si Ebute-Mẹta nibiti a npe ni Ago-Ẹgba ni Ebute Mẹtta titi di isisiyi. Ile Ọlọrun ti nwọn kọkọ kọ ti nwọn nṣe isin ni nwọn npe ni "Palm Church" (Ṣọọṣi oni imọ ọpẹ) l'Eko titi di oni, nitori imọ ọpẹ ni nwọn kọkọ fi kọ ọ.

Idi eyi ni o fi mu ki o jẹ awọn Ẹgba ni o kọkọ mu Ọlaju-oniwe tabi ọlaju ololoyinbọ wọ Eko, ṣugbọn awọn Oyinbọ oniṣẹ-Ọlọrun ti wa si Eko ni nkan bi ọdun mẹdogun si aseko igbana (1952). Gẹgẹbi ọrọ Jesu ti o wipe ẹnikẹni ti o ba gba mi gbọ bi o tilẹ ku yio ye, bẹna ni o ri fun Iwe Irohin Yoruba.



S. M. ADEMUYIWA

* * * *

### IWE IROHIN YORUBA TITUN

Nigbati o di ọdun 1945, ni ọdun kẹdogun sẹhin nigbati Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Ọrun nṣe Olotu Iwe Irohin "Daily Service" ni o tun da Iwe "Irohin Yoruba na silẹ ti o di araba nisisiyi ti apa ko ka a mọ.

Lati igba ti nwọn si ti da Iwe Irohin Yoruba titun yi silẹ ni o ti nṣe alagbọrandun gbogbo awọn ti iyab a nje, ti o ti nṣe eti fun aditi ati ẹnu fun odi ati akọya fun awọn ti o wa ninu igbekun iJiya.

Lati igbati Iwe Irohin Yoruba titun yi ti njade ni o si ti nkesi gbogbo enia lati mọ iyatọ ti o wa larin awọn ẹgbẹ oṣelu ti nfi otitọ ati iberu Ọlọrun ṣe iṣẹ iṣelu ti ọpọlọ wọn si pe, ati awọn ẹgbẹ oṣelu ti nwọn nfi ẹtan gba iranlọwọ awọn ara ilu, ti nwọn yio ma a daba ohun nlanla ti nwọn yio ṣe fun awọn ara ilu ti awọn ba le di alakoso, ṣugbọn ti o jẹ wipe ti ọwọ wọn ba ba eku ida tan, nwọn a ma a wa sọ pe awọn ẹgbẹ oṣelu kan ni o ndi awọn lọwọ ti ko jẹki awọn le ṣiṣe iṣelu awọn tanra gẹgẹbi ileri awọn.

Bayi ni Iwe Irohin Yoruba titun yi nlepa alafia gbogbo ilu Naijiria titi ti o si fi di aseko ti a wa yi ti a si gba ominira. Nko tun le ṣẹṣẹ ma a sọ fun nyin mọ, gbogbo akitiyan lati fi ọna han awọn ti ko mọ ọna, lati fi imọ fun awọn ope ati lati fi imọlẹ han fun awọn ti o wa ni okunkun ati lati fi awọn ti o npe okunkun ni imọlẹ ati imọlẹ ni okunkun han araiye titi ti a fi gbe e de aye Ominira Apapọ Ijọba Naijiria yi.

Igbagbọ wa ni pe ki awọn enia ti nfun Iwe Irohin Yoruba ni iṣiri nipa fifi eti si ohun ti iṣe ododo, ki a si tẹle e gẹgẹbi ọrọ Ọlọrun ti o sọ wipe "Ẹ wadi ohun gbogbo daju ki ẹ si di eyiti o ba nṣe otitọ mu". Ẹ ma a tubọ tẹramọ Iwe Irohin Yoruba ni kika ni igbagbogbo, bi o ti ja fun Ominira ti a ti gba yi ni yio si tun ma a ja fun idẹra ominira lọ titi.



*Eyi ni aworan igbati Alhadji M. K. Ekemọde nṣe isin fun awọn Musulumi ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni Gbalansa ọdan. Alhadji Ribadu, Ọba Adele Keji Eko ati Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria wa nibẹ.*

# Ori lo mọ ṣe

(Lati ọdọ ewe kọkanla) Laipẹ jẹhin re, Iyawo si loyun nitootọ.

Ereni, awada ni, Iyawo kekere na bi ọkunrin kan gẹgẹbi asọtẹlẹ Babalawo na. Ṣugbọn gẹgẹbi ọrọ ti awọn agba atijọ fi ma a nṣe owe pa bayi pe:- "Bi a ti nyọ ọ wi, ni nwọn nyọ ọ gbọ."

Aṣe gbogbo ọrọ ti o wa ni ipamọ nipa ọmọ-tuntun yi ni o ti han si gbogbo awọn Iyawo yoku pẹlu awọn ọmọ baba na, to bẹ ẹ ti nwọn fi bẹrẹsi fi ọrọ na dapara wipe. "A dupẹ o, ọba wole de, a dupẹ o!"

Bayi ni nwọn bẹrẹsi fi baba na ati ọmọ-tuntun na ṣe yẹyẹ ni ojojumọ titi ti ọmọ na fi ndagba dẹdẹ.

Ololu, o digba kan na.
(Koi ti pari o)



*Aworan Ile-onjẹ oniyebiye [ Federal Palace Hotel ] ti nwọn ṣi etikun niyi. Nibẹ ni awọn enia pataki pataki lọ jẹun lasiko Ominira Naijiria*

FEDERATION OF NIGERIA
1ST OCTOBER 1960
INDEPENDENCE DAY

On this historic occasion
The Nigerian Plastics Company Ltd. extends
Sincere Congratulations and Good Wishes
to Nigeria and all her Citizens

*To mark this great event, the Nigerian Government is presenting 3½ million souvenir Independence Beakers to school children throughout Nigeria. Nigeria's own Plastics Company is proud to have been entrusted with this important contract. An indication of other activities of the Company can be seen at Stand No. 185 in the "Made in Nigeria" Pavilion at the Nigeria Exhibition.*

NIPOL THE NIGERIAN PLASTICS CO LTD

# OMINIRA ATI ISIN

(Lati oju ewe kẹwa)

## ISIN IBILẸ

A le fi ohun kan tabi meji ṣe apẹrẹ. Ekini, awọn isin ibilẹ wọnyi tẹnumọ pe ajumọ gbe pọ, ajumọ ran ara ẹni lọwọ, ohun pataki ni. Bi a ni ilẹ kọ, gbogbo ẹbi ni yio de, gbogbo ẹbi, t'ọkunrin dawọpọ lati kọ ọ. Bi ikore t'obirin ni yio mura si iṣẹ.

Agbajọ ọwọ ni a fi i sọ aiya. Isin ibilẹ tẹnu mọ eyi pupọ. Ninu ẹba kanna, tabi ninu ilu kanna, nwọn le ma a sin orişirişi orişa, şugbọn eyi ko ya wọn ni ipa tabi ki o tu ilu ka.

Isin ibilẹ ni eewọ. Awọn eewọ wọnyi ni a fi şe ẹsọ iwa hihu. Ohun ti o lodi si eewọ ilu, ẹnikẹni ko gbọdọ şe e. Awọn eewọ wọnyi lagbara tobẹ ẹ ti nwọn fi şe amọna iwa rere fun awọn ọdọ ati awọn aşẹşẹ dide. Şugbọn awọn eewọ na ati awọn orişa ti nwọn jẹ mọ ọ ko lagbara mọ nisisiyi bi ti atijọ.

Ni igba laılai eewọ ni lati mu ọja ti a fi si oju ọna ti a si pa aie le e lori. Enitı o ba şe e nwọn gbagbọ ni igba na pe, yio ku.

Şugbọn ko ma ri bẹ ẹ mọ nisisiyi, bi o tilẹ jẹ pe ni agbegbe pupọ ni isin ibilẹ şi lagbara.

Ohun kan ti o lagbara ninu isin ibilẹ ni pe o tẹnumọ pe yiye ni awọn ẹni nilẹ yio ye. Eyi han gbangba ninu owe wọn ati adura wọn. Nwọn a ma a wipe: "Ninu ofii ati ọlan ni ọmọ pandọrọ fi ngbo". Nwọn a ma a wipe: "Peregede l'a o ye." Nwọn a si ma a şadura pe: We e ni ku (Iwọ ko ni ku), wee ni run (Iwọ ko ni run), waa ye (iwọ yio ye e). Ipilẹ igbagbọ isin ibilẹ ni pe yiye ni ao ye. Isoro le wa, ipọnju le wa, şugbọn gbogbo eyi yio rekọja yio si di ayọ.

## IGBAGBỌ ATI IMALE

Isin Igbagbọ ati Isin Imale si ti de ilẹ wa. Awọn mejeji si ti tubọ fi okun si isin ni ilẹ wa.

O le ni ọgọrun ọdun ti isin igbagbọ ti nşişẹ ni ilu wa. Ontẹnumọ pe ohun pataki ni isin totọ, isin ti o ga, ni lati jẹ ninu igbesi aiye wa. O tẹnumọ pe, a ni lati ni ominira, ki a bọ



DỌKITA J. O. LUCAS

* * * *

lọwọ ẹşẹ ti i sọni di ẹru, ti ki i jẹ ki a le şe rere. O nfi ọna imọlẹ han ni ki a ma şe bin ninu okunkun.

O nfi hanni pe; "Ododo ni igbe orilẹ-ede leke, ẹşẹ . si ni itiju awọn enia."

O daju pe ninu ijakadi fun ominira isin şe iranlọwọ pupọ. On ni o fun awọn akikanju ominira ni okun lati ja, lairi nigba idamu, ati idaniloju pe, dandan ija na yio yọri si rere.

## AWỌN OŞELU WA

Awọn aşiwaju ninu işẹ ilu ja kikan, ki ominira to tẹ wa lọwọ. Şugbọn bi ko şe pe agbara isin wa fun wọn, ti o ran wọn lọwọ bi agba isin ko ba si fun awọn ara ilu, ti o tẹle wọn, ki gbogbọ wọn si fi otitọ inu şişẹ, ki gbogbo wọn le fi imọ şọkan, fun ire ilu wọn, ominira ko ni le de.

**Ọpẹ nla ni gbogbo wa ni lati da fun ominira ti o de yi. A ko le şe aiyọ, ki ori wa si ya gaga. A ko gbọdọ gbagbe pe ẹru nla nla ni anfani ominira di ru ilu yi. Ọmọ ibilẹ ni lati gbe ẹru ilu ru. Ko tun si pe** a ma a rojọ pe awọn Oyinbo abi awọn ajeji ni ko jẹki nkan lọ gere mọ.

Ọwọ wa ni işẹ na wa. A ti de ori oke ko to ki a le duro lori rẹ. Gele ko dun bi ka mọ ọ we. Agbada ko gbadun bi ki a mọ ọ sọ si ejika, ki ẹgo awọtẹlẹ je han. Anfani ominira ko dun bi ki a mọọ lo. Bi a ba si ti şe e si, bẹni yio ri fun ilu wa ti yio si san gbogbo wa.

Ki a le lo anfani na darandara a nfẹ iranlọwọ ti isin nfunni. Isin ti o lagbara ni ipilẹşẹ ilọsiwaju. Isin na ti şe iranlọwọ pupọ lati ẹhin wa. A ni lati di isin wa mu girigiri, ẹkọ ti i gbeni ga ti o si fi kọ ni, a ni lati lo o, ki o le fi otitọ inu ati iwa ododo şişẹ fun ilu wa, ki a si le ma a fi ifẹ ba ara wa gbe, ki ilu wa ki o le toro, ki ọpa ẹbiti ilu wa ki o le ma a re siwaju ati siwaju, ki alafia tubọ le ma a gbilẹ ni ilu wa.



*Ọmọ-ọba Alexandra ngbadun bi Hausa ti şe ngun ẹşin rẹ ti o si fi ndabira. Aworan yi fihan bi Ọmọ-ọba na ti şe tẹju mọ Hausa-ẹlẹşin na.*




ALAFIA

de ni ikẹhin!

kuro lọwọ awọn ẹsanra ati awọn irora



Ki o le gbadun aiye, ara rẹ nilati da-saka gan an. Idi niyi ti o fi yẹ ki o ni TISANE de DURBON. On ni atelẹşẹ iyanu ti o dara fun o gan an. Nitorina gba ara rẹ kuro lọwọ airigbera. Fi opin si awọn ẹsanra ati irora wonni. Ma a mu TISANE de DURBON ni ojojumọ ki o si gbadun ara rẹ laara pẹlu iyanu.

Ma a gbadun ilera ati okun - inu titun

TISANE de DURBON jẹ asanse egbogi lati inu ewe ati ewebe. O jẹ wọn jẹ nkan mimu ti o gbadun ti o si ... fun anfani ẹda. Ni pẹlẹpẹlẹ, şugbọn pẹlu idaju saka ni yio fi tun ẹjẹ rẹ şe, yio lo awọn abawọn ti ko ni alafia kuro ni awọ-ara rẹ. TISANE de DURBON jẹ gbajumọ kakiri gbogbo agbaiye. On ni egbogi ilera mimu ti o dara julọ ti o le ra, ti o si le gbadun rẹ de opin.




TISANE de DURBON



EGBOGI IYANU ATẸJẸŞẸ

D. P. L. Ltd. 1, Aerodrome Road P. M. Bag 1006 APAPA

# Ija Ọbaro Kabba d'opin

NINU iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ ti o kọja yi, aṣoju iwe Irohin Yoruba ni Kabba, Ọgbẹni Michael B. Aṣaju bẹrẹ itan bi ija dibo yan Ọbaro Kabba ti ṣe bẹrẹ.

Ni ọsẹ yi, aṣoju wa sọ nipa bi ọjọ ibi Ọbaro titun yi, bi o ti ṣe ka iwe, ati awọn iṣẹ ti o ṣe nigbati o jade ni ile iwe. Itan Ọbaro na dun pupọ, yio si jẹ iwuri fun gbogbo awọn ọmọ Kabba.

Itan ọsẹ yi lọ bayi:—

Ni dede agogo mẹsan ku ogun iṣẹju ni mo de ọdọ Ọbaro titun pẹlu Ọgbẹni Emmanuel Olubiyọ. O si mu wa lọ si oke pẹtẹsi rẹ. Lẹhin igbati a ki ara wa tan, ni mo wa sọ fun

## Ọba Daniel Aka pẹ pupọ ninu iṣẹ Ijọba

*[Lati ọwọ Micheal B. Aṣaju, Aṣoju Iwe Irohin Yoruba]*

Ọbaro titun na wipe mo wa lati kọ itan igbesi aiye rẹ ati lati mọ kini nkan ti o ro nipa oye ti nwọn fi jẹ yi.

Mo si tun sọ fun un wipe emi yio fẹ mọ ira iṣẹ ti yio ran si awọn enia rẹ kakiri agbaiye.

Ohun kini ti mo kiyesi ni wipe Ọbaro titun yi gẹgẹbi Onigbagbọ (Christian) ko gbagbe ẹsin rẹ. Eni ti o kọkọ wi wipe, "Mo dupẹ lọwọ Oluwa".

Idahun kini ti Ọbaro fun mi ni wipe ki mba oun sọ fun gbogbo awọn ọmọ Owe kakiri agbaiye pe ki nwọn wa nirẹpọ, 'nitoripe ni aseko ti a wa yi isowọpọ ṣe nkan ni ngmu nkan dara. O ni bi ija ọdun kẹfa di de opin ni ọjọ kọkandinlogun oṣu kẹjọ ọdun yi, olukuluku ni lati mura girigiri lati ṣe iṣẹ daradara fun ilu wọn. O ni ki nwọn mu ija na bi ere bọlu afẹsẹgba.

Ọbaro na si sọ wipe ẹnikan ni lati gba ọkan wọle, eyi ni wipe ẹnikan ni lati bori ekeji nigbati o ba ti pe ti nwọn ti ngba bọlu na tan, nwọn yio wa bọ ara wọn lọwọ gẹgẹbi ọrẹ.

Ọbaro tun sọ wipe aseko to fun gbogbo ọmọ Owe lati gbe orukọ ilu wọn yọ nipa iṣẹ rere nibikibi ti nwọn ba gbe wa. Lẹhin eyi ni o tun wa ko awọn iwe ati waya ti o ti gba nigbati o di Obaro.

Ninu awọn waya ti mo ka ni mo ti ri eyiti o ti ọdọ Olotu Ipinlẹ Ariwa Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello wa. Bakanna ni mo tun ka eyiti o ti odo awọn Ọba Pategi, Kano, Bauchi, Yola, Fika ati Bida wa. Bakanna ni eyiti o ti ọdọ awọn ọmọ ẹgbẹ Kabba Owe wa lati orisirisi ilu. Bakanna ni eyiti o wa lati ọdọ ọrẹ ati ojulumọ wa kakiri ilẹ Naijiria.

Ninu waya ti Olotu Ipinlẹ Ariwa fi ranṣẹ, o ran Ọbaro titun na lati wipe ki o fi anu ati irẹpọ ma a ba awọn enia rẹ lo ki o ma si ṣe yan ẹnikan ni ipọsi nitori ẹgbẹ oṣelu.

Ninu esi iwe rẹ Ọbaro titun yi ṣe ileri lati wa irẹpọ awọn enia on, ati lati ma a wa alafia wọn pẹlu. Gbogbo waya ti mo ka ti Ọbado titun yi ri gba ni ọlọ mọkanla jẹ mejileladorun (92) bakanna si ni lẹta ti Ọbaro yi ri gba le ni ẹgbẹrun. Awọn ti o ti gba l'alejo pọ pupọ.

wa fẹnu kan igbesi aiye rẹ. Nwọn bi Ọba na ni ọdun 1905 ni ọdun marundinladọrin sẹhin, ni ilu Kabba. Ni adugbo Aganmọ ni nwọn si bi i si. Orukọ baba rẹ ni Obafọhun Aka. Orukọ iya rẹ ni Dorcas Wonisehin.

Ni ile iwe ti C.M.S. Oke Bọla ni ilu Ibadan ni o ti bẹrẹ iwe kika ni ọdun 1916, ọdun mẹrinlelogoji o si lọ si Holy Trinity School Lọkọja ni ọdun 1919. O pari ẹkọ rẹ ni ọdun 1921. O bẹrẹ iṣẹ olukọ kekere ni Lọkọja ni


M. B. AṢAJU

1922. O tun lọ bẹrẹ iṣẹ olukọ rẹ ni ilẹ Akoko ni ọdun 1924. Ni ọdun ti o tẹle ti iṣe 1925 ni o fi iṣẹ olukọni silẹ, o si bẹrẹ si ṣ'owo.

Ọbaro titun yi ko ṣaini iṣoro ninu aiye rẹ. Gẹgẹbi o ti pitan ara rẹ, o ni on fun rara on ni on ran ara on lọ si ile-iwe, o sọ wipe ni aseko igbati on lọ si ile iwe, awọn obi on ko fẹ wipe ki on lọ kọ ẹkọ sugbọn emi ilọsiwaju ti o wa ninu on mu on lati sa kuro lọdọ awọn obi on lọ si ilu Ibadan.

### ṢILE MEJE-ABỌ OWO OṢU

Ni igbati Ọbaro titun na nṣe iṣẹ olukọni, o ni ṣile meje-abọ ni on ngba ni owo oṣu. Ninu ọdun 1926 ni Oloye Aka bẹrẹ iṣẹ ni abẹ Ijọba Ibilẹ Kabba titi o fi gba isinmi ni ọdun 1953 lẹhin igbati o ti lo ọdun mẹtadinlọgbọn ninu iṣẹ na.

Nigbati o bẹrẹ iṣẹ ni abẹ Ijọba Ibilẹ Kabba nwọn gba a gẹgẹbi akọwe t'o nbu owo ori (assessment clerk) o ṣiṣẹ na fun ọdun meji gbako, ki o to bọ si iṣẹ akọwe kotu. O si ṣe e fun ọdun meje ki o to wa di igbakeji akapo (assistant Treasurer) fun ọdun mẹrin. O si tun bẹrẹ iṣẹ itọju ohun ini Ijọba Ibilẹ (store keeper) fun ọdun mẹrin.

Ni ọjọ kini oṣu kẹrin ọdun 1943 ni o bọ si ipo akapo Ijọba Ibilẹ Kabba (Treasurer) titi o fi gba aye isinmi ni ọdun 1953. Ninu ọdun na ni Oloye Aka di ọkan ninu awọn aṣoju Ijọba Ibilẹ Kabba (Kansilọ), ni ọdun 1957 nwọn yan an ni igbakeji alaga kotu kotẹmilọrun ti Kabba, ninu ọdun kanna yi si ni nwọn tun yan an lati lọ kọ ẹkọ British Council ni ilu Kano. Ki o di Ọbaro ti Kabba, Oloye Aka ni alaga ti nwọn yan fun Ijọba Ibilẹ Kabba.

KOI TI PARI)



# ITAN EKO

(Lati oju ewe keję)

o fi igboiya ati inu rere rę şę yi.

Nitori eyi, nigbati Aşipa fę pada bọwa lati Ibini, Onibini si fi i ję ọgagun awọn ọmọ-ogun rę ti bę ni Iddo ati awọn ti o tun yan fun un, bi ẹmẹwa rę lati ba a wa. O fi ilu Gbẹdu kan, eyiti nwọn i ma a lu fun ba Eko, ati Abere kan ti Oba i ma a fi jo fun un. Awọn ọmọ Aşipa ti nwọn nrọ ipo rę li a npe li Ọba Eko titi di oni-oloni.

**BI EKO TI ŞE DI AMU ILU**

Ọkan ninu awọn ọmọ Ọlọfin ti nję Aromirę li ẹniti o kọ wa mu ilę ni erekuşu Eko. O fẹran lati ma a wa dẹja ni Ebute Ero. Bi o ba dẹja tan a si ma a zinmi fun igba-dię nibę ki o to pada lọ si ile (Iddo).

Nigbati o ngbadun Ebute-Ero lọjọ ti o ti pę, o pa agọ sibę, o si mu awọn enia rę wa sibę, nwọn si jumọ ngbe ibę. Lẹhinna ni Aromirę rohin ibę fun Onitana ati Onitọlọ, awọn ọmọ baba rę ti nwọn si ni ifę ara wọn gidigidi.

Aromirę ni aye wa fun wọn lati pa agọ tiwọn lọtọọtọ bi nwọn ba fę. Onitana ati Onitọlọ si ba a wa si ibę. Onitana pagọ si Ebute Idumọta; Onitọlọ si pagọ si Ebute Itọlọ. Nibę ni nwọn i ma a sinmi ti nwọn ba şişę tan. Ọgangan Isalę Eko ni Aromirę fi da oko rę ti o si gbin orişirişi ohun ọgbin ati ewebę si.

Nitorina ni nwọn ti şe npe Iga Ọba Eko lati igba na ni "Iga-Idunganran" Itumọ 'Idun' ni 'Ile', Itumọ 'Iganran' jasi 'ata'. Awọn iyoku ninu awọn ọmọ Ọlọfin ti a ti wi şiwaju pę, o da l'ọla nlọ mu ilę tiwọn, gẹgẹ bi awọn ibi ti a juwe sẹhin.

Nigbati o pę, Eko, ti itumọ rę ję oko ati ebute ipẹja fun awọn ti nwọn tę ę do, si bẹrẹsi kun fun awọn orişirişi enia lati awọn ilu okeere. Eteeti ẹbute, lati Idunmagbo titi lọ de Itọlọ li o kọkọ kun fun awọn enia.



Gẹgẹ bi a ... ni oju ewe kẹrin-dinlogun ninu iwe "Irohin Yoruba" ọsę yi, Ọmọ-ọba Alexandra ti işe aşoju Ọlọlajulọ Ọba Gẹẹsi Elizabeth Keji ninu ajọyọ Ominira ti Apapọ Naijiria gba lọjọ Abamẹta ti i şe ọjọ kini oşu yi şe abẹwo awọn ọmọ Ẹgbẹ Alagbelebu Pupa ni agbala-afin Gomina Agba l'Eko. Aworan ti o wa loju ewe yi ti igbati o mba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ. Ariya ọjọ na dun, o larinrin, irohin ke to afojuba ni, yio si ję ohun iranti nla fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na.



# Ayọrisi idije orire

[illegible]

## AKIYESI PATAKI

A fẹ ki gbogbo ẹnyin aṣoju wa ati onkawe kakiri agbaiye ma a fi irohin pataki ti o ba ṣẹlẹ ni ilu ti ẹ ngbe tabi itan aladun sọwọ si wa. Ki ẹ si gbidanwo lati ma a fi fọto irohin na sọwọ si wa ki ẹnikẹni le ri idaniloju ohun ti o ṣẹlẹ na, ati aworan na ati irohin na lọfẹ ni a o tẹẹ jade fun nyin. Ajunmọṣe wa ko ni bajẹ o. OLOTU

INDEPENDENCE

is

NATIONAL . . .

NATIONAL

BANK

is

INDEPENDENT

Congratulations

to

ALL NIGERIANS


A ki yin o
pẹlu ifẹ inurere si
IJỌBA ATI AWỌN ARA ILE OMINIRA
NIGERIA
O dúnmọ́ ẹjọ United Africa Company fun ajọgbe pọ̀ timọ timọ
pẹlu Nigeria lati ọjọ pipẹ, wọn si bá
Orilede na yọ̀ fun Gbigba Ominira.
Ajọ na tunbọ gbà tọkan tọkan wipe ire mbẹ
niwaju fun Orilede Nla yi.
THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED
THE UNITED AFRICA COMPANY LIMITED

# PATERSON ZOCHONIS

## AND COMPANY LIMITED

ti nwọn ti nṣiṣẹ fun awọn enia Naijiria le ni

**ỌGỌTA ỌDUN**



. . . ki Ijọba ati awọn enia Naijiria ku-orire fun gbigba OMINIRA IJỌBA wọn ni ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun yi.

Bẹ aye ibudo wa wo ni Ile-Ifihan Naijiria




# Ominira fun t'ọkọ t'aya

### (Lati ọwọ Iyaafin Odutayọ)

Mo ki gbogbo nyin ku afojuba Ominira Apapọ Naijiria ti o bọ si wa lọwọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kini oṣu yi. Gẹgẹ bi aye mi bi obirin ni ile ọkọ ati gẹgẹbi mo ti ṣe jẹ ọkan ninu awọn alabaṣiṣẹpọ Olotu Iwe "Irohin Yoruba", ẹtọ ni fun mi ki nfun awọn t'ọkọ-t'aya ni imọran diẹ ti mo ri pe bi nwọn ba gba a yio fun wọn ni ominira ni abẹ ile wọn.


IYAAFIN ODUTAYỌ

* * * *

Ohun ti o mu mi ti mo fi fẹ mu imọran na wa ni pe "Lati ile ni a ti nko ẹṣọ r'ode" nitoripe bi a ba ni ominira ni abẹ ọdẹ ẹni nigbana ni a o to ni ayọ kikun ati alafia lati ma a gbadun ominira ni ita lọ titi....Nitori "Bi ile ko ba dun bi igbẹ ni ilu ri.'

Ki Ọlọrun Olodumare ki o lẹ ki inu gbogbo wa ki o dun, ki awa na si fi iwa wa ati iṣe wa, wa inu didun kan funra wa, nitori ẹniti ò ba ran ara rẹ lọwọ Ọlọrun O ran an lọwọ.

Imọran mi na ni pe, ki ọkọ ki o ma a du ni ọnakọna lati fi ọkan iyawo rẹ balẹ ni ile, ki iyawo paapa ki o si tun ma a sa agbara lọna-kọna lati ma a fi ọkan ọkọ rẹ balẹ. Iyẹn ni pe ki ọkọ ki o mọ ohun ti o tọ lati ma a ṣe fun iyawo rẹ ki iyawo paapa mọ ohun ti o tọ lati ma a ṣe fun ọkọ. Nipa bayi ominira yi sọkalẹ si abẹ ọdẹdẹ wọn.

Bi ọkọ ba lọ si ẹnu iṣẹ ki si doju kọ iṣẹ rẹ, ki o ma a ṣiṣẹ rẹ lọna ti yio fi ojurere awọn ọga rẹ, lẹhin ti o ba si ṣiwọ nibi iṣẹ na ki o ma a bọwa si ile rẹ taara ki o ma gba ile ọti lọ tabi ile iworan de aye ti iyawo rẹ yio fi ma a jaiya nile pe boya kini kan ni o ti ṣẹlẹ si ọkọ on ni ọna tabi o gba ile obirin lọ ni.

Bi ọkọ na ba yago fun aleebu wọnyi, o tọ ki iyawo paapa ko yago fun ohun ti yio bi ọkọ rẹ ninu ti o ba ti ibi iṣẹ de.

(KOI TI PARI)







Eyi ni aworan Ọmọ-ọba Alexandra nigbati o ndagbere fun Ọlọla Tafawa Balewa Alakoso Ijọba Naijiria ki o to lọ si Ibadan

# IWE OFIN

(Lati oju ewe keji)

mu iro rere wa lati ọdọ Ọba Gẹẹsi, eyiti o fi si eti gbọ gbogbo ara ilu ni ọjọ ominira ti iṣe ọjọ kini osu yi ni gbangba ọdan.

Ni ọjọ na ni Gomina-agba, Ọlọla James Robertson tun arabu gẹgẹbi Gomina-Agba Naijiria.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni Ọmọ-ọba Alexandra ṣe isin ni Sọọṣi Anglikan, l'Ebute Ehingbeti. Eni-owọ Ọlọla julọ Bishopu Howells lo ṣe akoso isin na. Ni agogo marun abọ ọjọ na, awọn elere oju omi ọlọko-ajẹ ṣe ariya fun Ọmọ-ọba yi nipa fifi ọkọ ti nwọn ṣe ọṣọ si dada loju omi, eyiti awoṣan nwọn ti jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti ọsẹ ti o kọja. Nwọn ṣe ere ọkọ-ajẹ na titi di agogo meje asalẹ. Ero si pọ bi omi ti nwọn wa woran.

Ariya wonyi de opin l'Eko ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi nigbati Ọmọ-ọba Alexandra si ile Igbimọ Asofin Apapọ Naijiria ni deede agogo mẹsan owurọ. Lẹhin na ni Ọmọ-ọba yi fi moto-ayọkẹlẹ na'sẹ yika ita Tinubu, ki o to gbera lọ si Ipinlẹ Iwọ-Orun nibiti yio wa titi di ọjọ kẹfa oṣu yi, ki o to lọ si Ipinlẹ Ila-Orun. Ibẹ ni yi si gba de Ipinlẹ Ariwa.



Ọmọ-ọba Alexandra ati Gomina Agba ti Naijiria


# BI A TI ṢE LE GBIN ỌPỌLỌPỌ KOKO





O LE GBẸKẸLE 'GAMMALIN' 20

PLANT PROTECTION LTD


## AKIYESI FUN ONKAWE

Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin o n k a w e ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o ma a kọ ọ taara si ile iṣẹ rẹ ni:

**Allied Newspapers Limited,**
**Elephant House**
**214, Broad Street, Lagos**



Aworan yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Alexandra nka iwe ti Ọlọla-julọ Elizabeth Keji fi ki Naijiria ku orire ti Ominira ni gbangba ọdan l'Eko

# Naijiria di ominira

NIGBATI o di agogo mejila oru ọjọ Eti ti ise ọgbọnjọ oṣu kẹsan ọdun yi, ni nwọn ka asia Gẹẹsi walẹ. Lẹsẹkẹsẹ ti ọjọ Abamẹta wọle, ti i ṣe ọjọ kini oṣu kẹwa odun yi ni asia Naijiria go'ke.

Gbara ti asia Naijiria ti gun oke, ni gbangba ọdan l'Eko nibiti wọn gbe bẹrẹ ajọyọ ominira na nigbogbo enia ti bẹ fun ayọ, ti nwọn si nkọ odi orilẹ ede Naijiria awọn ologun Naijiria si nrọ agba, awọn ọlọkọ oju omi Naijiria ti ọkọ wọn wa ni oju omi ọsa l'Ehingbeti si bẹrẹ si fun fere.

Nwọn si ṣe aṣeyẹ yi di agogo mejila-abọ mojumọ ọjọ ominira na. Nigbati o tun di owurọ ominira, nwọn tun bẹrẹ eto gbigba ominira na, Ọmọ-ọba Alexandra ti o ṣe aṣoju Ọlọla-julọ Elizabeth Keji, Ọba'birin Gẹẹsi si jiṣẹ Ọba'birin Gẹẹsi na fun gbogbo Naijiria, pe inu on dun ti Naijiria di ominira. Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria si sọrọ lori ominira na bi inu gbogbo Naijiria ti dun to.

Nigbana ni Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria sọrọ ajọyọ pupọ lori ominira na. Lẹhinti nwọn pari ẹtọ yi, ni nwọn ba tuka ti gbogbo ilu si bẹrẹsi yọ ayọ na kakiri igboro Eko. Irohin ko to afojuba ni ajọyọ na jẹ kakiri gbogbo Eko.

Ki Oluwa ki o pẹlu wa ninu ominira na, ki ile gbogbo wa ko si ni ominira kalẹ.



Aworan yi ni ti igbati Ọmọ-ọba Alexandra Ọbabinrin Gẹẹsi Elizabeth Keji nki awọn ọmọ ile-ẹkọ ti nwọn wa ṣe ariya fun ni gbangba ọdan

## Seriki Ọtta fun Ansar-ud-Deen ni £25. 5. 0.

ỌTTA

LENULỌLỌYI ni awọn Ẹgbẹ 'Young Ansar-Ud-Deen' lọ fi ipilẹ Mọṣalaṣi nla kan lelẹ ni Ọtta. Ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ na ati awọn enia jankanjankan ni Ọtta ati agbegbe rẹ lati Eko ni o pe ṣoṣo sibẹ.

Lẹhinti nwọn ti gbadura tan, ni nwọn wa fi ipilẹ na lelẹ pẹlu oruko Oluwa. Alhadji Oloye Shittu Bashọrun, Seriki Ọtto si fun awọn ẹgbẹ na ni ponun mẹdogbọn ati ṣile mẹdọgbọn fun iranlọwọ.

Published by Allied newspapers Limited, Elephant House, 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" odun kan—Eko ṣile mefa ati kobo meje (2/6d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun ṣile metala (13s.) Olotu S. M. Adesunyiwa, 2, Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.